# Omi To N Fi Igba-Gbogbo Wá Lati Inu Apata

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Kẹtalelogun, Oṣu Keje, 1961

1 A dupẹ ni owurọ yi fun ifarahan Oluwa Ọlọrun ti yoo bẹrẹ awọn isin owurọ nipasẹ bi O ti ran iṣẹ kan si wa, pe ki a feti-silẹ, ki a wa ni ibọwọ niwaju Oun, pe Oun ni ohun kan lati ba wa sọ. Mo ni idaniloju pe yoo ṣe ohun ti O ti ṣeleri. Igba gbogbo lo n pa Ọrọ Rẹ mọ. Nitorina a dupẹ lati korajọ papọ, laaye, ni iha ainipẹkun ni owurọ yi, ti a lee jọsin si Oluwa lẹẹkansii ati lati ko arawa jọ ki a lee gbọ lati ọdọ Rẹ. Idi ti a fi darapọ niyi, fun idi yi paapa.

2 Bayi, mo pe Arakunrin Neville lairo-tẹlẹ nitori àlá kan ti mo la. Mo gbagbọ ninu ala. Mo gbagbọ pe Ọlọrun maa n farahan awọn eniyan nipasẹ ala. Mo si lá àlá kan to ṣajeji ni òru ijẹta, mo rii pe mo nlọ ni iha oke kan, iha oke kan pato, mo nlọ si ile ounjẹ kan nibiti mo ti fẹ jẹ ounjẹ alẹ. Mo si sakiyesi pe, bi mo ti sunmọ ibẹ, wọn n gbọ orin, akọrin-ibilẹ kan nkọrin pẹlu ohun elo orin faolin, o si n da awọn eniyan láraya bi wọn ti n jẹun. Ohun kan si wà nipa rẹ ti nko fẹran, nitorina mo fi i silẹ. Mo si pade eniyan kan to mbọ lati ori-oke kan. Mo si wo o, ọpọlọpọ lo n wa si ile ounjẹ yi lati oke naa. Ṣugbọn mo kuro laarin wọn, mo kọju si apa-ọtun ... Tabi si apa-osi.

3 Ni ọna-kan, ni afonifoji, mo lee ri ile ijọsin yi. Mo gbọ ohun ẹnikan ti o sọ pe, "Ẹ pade Arakunrin Branham ni ikorita kan - o n bọ lati ori oke lọhun - ki ẹ si sọ eyi ati iyẹn fun un." Mo si ṣe kánkán lati de ikorita naa.

Nigbati eniyan naa si wa, o jẹ Arakunrin Neville, o wọ aṣọ alawọ omi-koko, irisi rẹ jẹ bi o ti ri ni owurọ yi. O si wipe, "Arakunrin Branham, ti iwọ yoo ba wa ni inu ilu, "Pe, "Yoo jẹ ohun daradara fun ọ lati wa nitoripe Arakunrin Hank ..." (Nisisiyi, ẹnikanṣoṣo ti mo mọ to n jẹ "Arakunrin Hank" ni Arakunrin Henry Carlson. A maa n pe e ni "Hank.") O wipe, "O lee ro pe o ṣajeji pe iwọ ko ṣe abẹwo si ile ijọsin mọ́ pupọ nigbati iwọ ba wà ni ayika ... ti o wa ni inu ilu fun ọjọ diẹ." Mo si taji.

Nitori eyi, mo ni imọlara to ṣajeji. Nko fẹ wa ni akoko yẹn ninu ọsẹ. Mo beere lọwọ Arakunrin Neville ti o ba ni ohun kan to ṣe Pataki fun ijọ ni owurọ yi. Nitorina, o ni inu rere, bi o ti maa n ri nigba gbogbo, o wipe, "Maa bọ." Nitorina, a wa. Mo pe e ni irọlẹ ana, mo si wa ni owurọ yi, o jẹ ohun ti ẹnikẹni ninu wa ko ro tẹlẹ.

4 Mo gbagbọ pe yoo jẹ ohun rere, lakọkọ, fun mi lati ṣalaye awọn ọrọ kan fun yin. Mo dabi ẹniti o ṣajeji si ọpọlọpọ eniyan. Emi pẹlu si ṣajeji si arami, nitoripe mo gbiyanju lati tẹle idari Ẹmi Mimọ bi mo ti lee sun mọ ọn to, eyi si n mu ki a ṣajeji. A n ṣe awọn ohun kan to n mu ki a joko, ki a si maa ronu nigbamiran, pe, "Eeṣe ti mo ṣe iru nkan bi eyi? Bawo ni mo ṣe ṣe iru nkan bẹẹ laye?" Nigbanaa, o lee ro pe o ti ṣe ohun ti ko yẹki o ṣe gẹlẹ. Ṣugbọn ti iwọ yoo ba ni suuru, ati igbagbọ, ti o si da ọ loju pe Ọlọrun ti dari rẹ lati ṣe e, iwọ yoo ri i pe ó ṣe bi o ti yẹ gẹlẹ, ṣe ẹ rii. Ni ọpọlọpọ igba ni a si n ri eyi. Mo mọ pe Arakunrin Neville pẹlu ti ri eyi ni ọpọlọpọ igba, awọn adari ati awọn ẹni ẹmi si loye eyi.

Awọn akoko kan ti wa ni aye mi ti ... Lootọ, lati igbati mo ti jẹ ọdọ, nko ti i ni idari lati gbe ni ilu Jeffersonville. O maa n jẹ ohun ti ko bami-laramu, fun mi lati gbe ni ilu yi. Lakọkọ, oju ọjọ nihin ko ba mi laramu. Ohun miran nipe, o dabi ẹnipe ọ̀ọ̀rìn ẹmi kan wa.

5 Ti ẹ ba lọ ti ẹ si wo ibikan nihin, ti ko ba bajẹ ni akoko ikun-omi, lẹta kan wa ti mo kọ nipa eyi ... Ipe akọkọ ninu iṣẹ iranṣẹ. Mo nlọ. Arakunrin George DeArk ati emi.

Iya Arakunrin Graham Snelling, Arakunrin Hawkins, ẹniti o ni ile epo bentiro kan ni ilu New Albany, ọpọlọpọ awọn eniyan ba mi pade nibikan, nibi ipade adura. Wọn si sọ pe ti n o ba duro, awọn o din ounjẹ awọn ọmọ awọn kù lati kọ ile ijọsin kan fun mi, ki a ma ba maa fi afẹfẹ oniruuru ẹkọ gbe wọn kaakiri.

6 Nigbati mo gbọ pe iya kekere kan, to n gbe ọmọde kan si ọwọ ọtun ati ikeji si ọwọ osi rẹ, ti o sọ pe oun yoo din ounjẹ awọn ọmọ awọn kù, ki wọn lee kọ gbọngan kan ti wọn o ti maa jọsin, o ṣoro fun mi diẹ lati farada eyi. Nitorina Arakunrin George ati emi parapọ, a si pinnu pe a o duro lati kọ ile ijọsin yi.

Nigbati a si kọ ile ijọsin yi ... Ni owurọ ọjọ ti mo ya a si mimọ, mo ri iran kan nibi okuta igun ile lọhun, eyiti mo kọ silẹ, nigbati Ẹmi Mimọ sọ fun mi pe, "Eyi ki i ṣe ile ijọsin rẹ." Mo si beere ibiti ile ijọsin mi wa, O si mu mi joko ni abẹ awọsanmọ alawọ omi-aro ti ko ni kurukuru. Lẹyinna ni O wipe, "Ṣe iṣẹ ajihinrere," ati bẹẹbẹẹ lọ, bi ẹ ti mọ. A tilẹ kọ ọ sinu iwe.

7 Gbogbo awọn nkan wọnyi lapapọ. Ni ọjọ kan nigbati mo n rin ni agbala lọhun nibiti Arakunrin Wood n gbe nisisiyi - iya iyawo mi n gbe nibẹ laoko naa - mo joko sibi atẹgun ẹyin ile, atẹgun kọnkere kan, ninu eyiti mo ti kọ ile kekere yi fun iya iyawo mi. Oun lo si dabi ẹniti n ṣi ilẹkun ile ijọsin lakoko naa, o n ṣe amojuto rẹ. Kedere, bi ẹnikẹni yoo ti sọrọ, ohùn kan tọmi wa, pe, "Nko lee bukun ọ laelae niwọn igbati o ba duro sihin. O ni lati ya ara rẹ sọtọ kuro laarin awọn eniyan rẹ ati ibiyi." Koburu, eyi fọ ọkan mi si wẹwẹ fun nkan bi ọsẹ kan tabi omiiran.

8 Nigba-gbogbo, ni gbogbo igba, ohun kan ti kilọ fun mi pe, “Lọ, lọ. Lọ si iha iwọ oorun. Maa lọ si iwọ oorun.” Koburu ... O maa n jẹ iyọnu fun mi.

Bayi, mo ti ṣe ipinnu kedere ni ọkan mi pe ni ọsẹ yi, mo n lọ si ilu Tucson, nibiti n o ti yá ile gbe, lati wa nibẹ ni akoko otutu yi, ki n si fi awọn ọmọ si ile iwe, bẹrẹ lati Oṣu kẹsan. Mo ti ni ile naa ti n o gbe. Wọn tilẹ fun mi ni ibikan nibẹ paapa.

9 Ohun miran ti n o fẹ lati sọ, ki a to kọ ile yi nihin, ile iranṣẹ Ọlọrun, nibiti o wa nisisiyi ... Nko fẹ kọ ile sibẹ nigbana. Iya iyawo mi ti dagba, iyawo si sọkun nipa rẹ paapa. O wipe, “Nko lee fi iya mi sihin, bi mo ti mọ pe o ti dagba, o si lee ma ri itọju.” Koburu, mo loye eyi. Mo loye rẹ. Iya rẹ ni - iya kanṣoṣo ti o ni, tabi ti yoo ni laelae - nitorina, mo loye eyi. Bẹẹ ni mo gbadura si Oluwa, mo sọ pe, “Oluwa, bi o ti jẹ pe nko fẹran ibẹ,” Mo wipe, “fun mi ni itẹlọrun. N o lọ si ibikibi ti O ba fẹ ki nlọ, lati ibikibi. Ṣugbọn nko fẹ ba iyawo mi ninu jẹ, lati mu kuro nihin lọ si orilẹ ede ajeji nibiti ko ti mọ ẹnikẹni. Ti emi si n rin irinajo nigba gbogbo botiwu-kori. Mu mi ni itẹlọrun lati wa nihin pẹlu rẹ.”

Nisisiyi, ti iya rẹ ti lọ simi, ti o ti lọ sinu ogo, imọlara naa tun tọmi wa, ṣe ẹ rii, lati tẹsiwaju. Nko mọ ohun ti n o ṣe.

10 Lẹyinnaa, lọjọsi nigbati ẹkọ ti awọn ara n gbe kiri nisisiyi ... Mo duro lati ori pẹpẹ lọjọsi, nigbati mo wa sihin gbẹyin, mo si sọ fun yin pe nko ni lọ fun ikiriwaasu titi ti ẹkọ òdì naa yoo fi ku. Bẹẹni, awọn ara si fi inu rere mu eyi tọ. O ti pari. Laarin wakati mẹrinlelogun ni o pari.

Bayi, eyiti ṣilẹkun ikiriwaasu fun mi lẹẹkansii. Nko mọ ohun ti n o ṣe, nko mọ ọna ti n o ya si. Mo ti beere lọwọ Oluwa fun iran kan. Mo ti bii lati sọ ohun ti n o ṣe fun mi, ṣugbọn O kan mu mi joko ni, ko tii sọrọ.

11 Bayi, laṣalẹ ana, nigbati mo ti ko awọn ọmọ, iyawo ati ohun gbogbo kuro ninu ile, mo jẹjẹ kan fun Oluwa, Ọlọrun. Mo si sọ fun Un, Pe, “Ti Iwọ yoo ba bukun mi ni ọna ti mo ba lọ, n o sin Ọ. Ṣugbọn Iwọ yoo fi ibiti n o lọ ati bi n o ṣe lọ han mi, ati ohun ti n o ṣe.” Nitorina, mo ya ara mi si mimọ fun Oluwa. Iṣẹ iranṣẹ ati ohun gbogbo, mo fi le Oluwa lọwọ. Mo si wipe, “Ibikibi ti O ba ṣi silẹ, ohunkohun ti O ba ṣe, n o rin ni ọna naa. Titi ti Iwọ yoo fi la ọna, n o maa tẹsiwaju bi mo ti n ṣe titi ti Iwọ yoo fi la ọna.” Mo si gbadura si i lati mu ki o han kedere ki a maa ba a tan mi jẹ, nitoripe mo gbagbọ, pe a wà ni ikorita ohun kan to fẹ ṣẹlẹ.

Mo gbọ ọ ninu asọtẹlẹ nihin ni owurọ yi nipaṣẹ Arakunrin Neville, tabi o sọ ọ nibiti mo ti mọ pe asọtẹlẹ ni o n tọka si. Bayi, nitorina, mo ti gbadura fun gbogbo yin, mo si nilo ki gbogbo yin gbadura fun mi ki Ẹmi Mimọ lee dari mi lọ si ibiti o yẹki nlọ gẹlẹ, ohun ti o yẹki n ṣe, ki n ma baa ṣe asiṣe kankan.

12 Ṣe ẹ rii, lọpọlọpọ igba, awọn eniyan maa n ro nipa ebun asọtẹlẹ, bi igbati Ọlọrun kan maa n sọ pe, “N o mu ọ lọ soke nihin, N o si mu ọ goke sihin, bayi goke lọ sihin ...” Kii sọ ohun gbogbo fun ọ. Ti o ba ṣe bẹẹ, igbagbọ aṣegun wo ni iwọ yoo ni? Ṣe ẹ rii, O maa jẹki o daduro, ju ẹlomiran lọ, ṣe ẹ rii. Gbogbo yin lee tọ mi wa, ki ẹ si beere fun awọn ohun kan, Oun ko si tii kuna ri ninu fifi idahun kan fun ni. Bẹẹni. Ṣugbọn mo lee beere nkan funra mi, lọpọlọpọ igba, O maa n mu ki n da duro, ṣe ẹ rii, O n mu ki n tẹsiwaju lati wọ inu ohun kan lọ.

Mo ni awọn ohun kan nisisiyi ti mo ni lati yanju funra mi, ati awọn ipinnu ti mo ni lati ṣe. Eyi si jẹ ohun to ṣe pataki pupọ, nko lee ṣe e gẹlẹ titi ti n o fi ni idaniloju pe Oun lo n sọrọ si mi. Oun ko si fun mi ni iran kankan. O kan fi mi silẹ ni. Bẹẹ ni mo n joko bi ọmọ alainiya, ni owurọ yi. Nko mọ ibiti n o ya si. Nitorina, Mo ti fi le Oluwa lọwọ.

13 Mo ni iru imọlara kan pe, lati la àlá bẹẹ, pe ki n pada wa si ile ijọsin nihin ki n si ran Arakunrin Neville lọwọ titi ohun miran yoo fi ṣẹlẹ loju ọna naa. Nitorina, N o maa wa pẹlu yin.

Mo beere lọwọ Arakunrin Neville ni iṣẹju diẹ sẹyin, nipa bi ijọ ṣe n tẹsiwaju.

O si dahun pe, “O dara.”

Bẹẹ ni mo si gbọ pe ẹ ni ẹbun ẹmi ati ohun bẹẹ sibẹ laarin yin, eyiti n sisẹ - ẹbun asọtẹlẹ, ifedefọ, itumọ ede, eyiti a gbọ nigba diẹ sẹyin. Awọn nkan naa si nfi ẹsẹ ijọ mulẹ, lọpọlọpọ.

14 Ṣugbọn mo ro pe boya ni aṣalẹ yi, ti Arakunrin Neville ... ti Ẹmi Mimọ ko ba dari wa sinu ohun miran, ni aṣalẹ yi n o fẹ la ... Ki gbogbo yin, ki ẹ to fi sọọsi silẹ ni owurọ yi, ki ẹ kọ ibeere ti ẹ ba ni, ki ẹ si fi silẹ nihin, ibeere ti o wa ni ọkan yin, ki a lee mọ ohun ti ijọ n ro. Ọna ti awọn oluṣọ aguntan maa n gba lati mọ ohun ti o wa lọkan awọn eniyan niyi. Ẹyin ti ẹ ba ni ibeere, ẹ kọ ọ ki ẹ si fi i silẹ nihin. Ti iwọ ko ba ni iwe ajakọ lati kọ ọ si ni owurọ yi, nigbana, kọ ọ ni aṣalẹ yi, kiakia. N o fẹ lati ni akoko pupọ lori wọn, lati ṣe ayẹwọ wọn, ki n si dahun wọn pẹlu Iwe Mimọ.

15 Nigbana, ti Oluwa ba fẹ, ti o ba jẹ ifẹ Ọlọrun, mo ti sọ gbolohun kan nihin nigba diẹ sẹhin pe n o fẹ lati ba

yin sọrọ lori awọn edidi mejeeje ti Iwe Ifihan. Bayi ti ... Nko lee pari alaye lori awọn edidi naa ni ọdun yi nitoripe o bẹrẹ lati ori kẹfa Iwe Ifihan titi de ori kọkandinlogun, lati pari gbogbo awọn edidi naa. Ṣugbọn mẹta tabi mẹrin akọkọ ninu wọn ni a lee ṣalaye laarin aṣalẹ kan, mo ro pe, o yẹki a ṣalaye ikọọkan laṣalẹ kọọkan.

16 Bayi, ti a ba loye rẹ, ṣe ẹ rii, ibiti a ti duro lori Iwe Ifihan naa, ni ibiti a ti mu ijọ goke lọ, iyooku si n sọ nipa awọn Juu, ki i ṣe nipa ijọ rara. O sọ nipa orilẹ ede Juu. Nitorina, a o ni lati bẹrẹ lati igbasoke ijọ, bẹẹni a ri i nihin, ohun ti o ṣẹlẹ ni akoko awọn edidi naa, ati akoko igba ijọ keferi, ijọ ti lọ nigbana. Ati pẹlu orilẹ ede Israẹli, o pada wa, O si mu Israẹli lati igbati O ti fi wọn silẹ, titi di akoko yi, ati nipa Messiah to mbọ wa, nigbati wọn yoo gba Messiah naa.

Bayi, ṣe o ye yin? A ti mu ijọ goke lọ. Ọlọrun kọkọ ṣe pẹlu awọn igba ijọ. Ati kẹkọ nipa iyẹn. Lẹyinna, a mu ijọ lọ sinu ogo. Lẹyinnaa ni Ẹmi Mimọ pada, ti O si gba Israẹli gẹgẹ bi orilẹ ede, ti O si mu u wa si ipele yi nigbati àsè igbeyawo n tẹsiwaju, ti O si mu wọn pada wa nikẹhin. N o gbe patako silẹ, ki n lee fi ṣalaye rẹ, ki n si kọ ọ, nigbati akoko ba to. Lẹyinnaa ni Oluwa yoo pada wa pẹlu iyawo, Israẹli yoo si ri iyawo Rẹ. Ah, iru akoko wo ni eyi yoo jẹ!

17 Bayi, ki a to lee ṣe alaye eyi daradara, ẹkọ nla kan wa ti o ti jẹ ohun ikọsẹ si awọn ẹlẹkọ Bibeli, ati ọpọlọpọ awọn olukọ Iwe Mimọ nigbogbo igba ijọ, awọn eniyan ijọ Kristi ati awọn to mbọ lati gbọ eyi. Iyẹn ni ẹkọ nipa ọsẹ aadọrin Danięli. Ati ni ... A ko lee wọ inu Iwe Ifihan lọ mọ titi ti a o fi so iyawo ati Israẹli papọ pẹlu ọsẹ aadọrin ti Danięli. Boya, ti Ọlọrun ba fẹ, ti O ba ba mi sọrọ ni ọjọ iwaju lati sọrọ lori awọn kan ninu aadọrin ọsẹ yi ... Ki i ṣe aadọrin ọsẹ, ṣugbọn awọn edidi meje to gbẹyin ... Nigbana ni ọjọ Aiku to mbọ, n o fẹ lati sọrọ lori aadọrin ọsẹ Danięli. Ni ọjọ Aiku to mbọ, bi Oluwa ba fẹ. Iyẹn ni yoo si ṣilẹkun fun awọn yooku, ti yoo ba dari wa lati bẹrẹ alaye lori awọn yooku. Koburu, a o mọ lati ibẹ lọ.

18 Arakunrin Neville ati emi yoo maa siṣẹ papọ lori eyi, ti a o si maa ṣe ohun gbogbo ti a lee ṣe fun anfaani awọn eniyan.

Bayi, bi a ti n pada, nigba kọọkan, a o maa gbadura fun awọn alaisan. A n layọ nigba-gbogbo lati ṣe eyi. Boya n o si maa ṣe bẹẹ nigba-gobgbo, ti ara awọn eniyan ko ba dá, lati gbadura fun wọn.

Nko fẹ lati maa ṣe imẹmi-yatọ mọ. Ṣe ẹ rii, ohun ti o ṣẹlẹ niyi. Mo ti gbiyanju. Mo mọ pe mo ti ṣe asiṣe; ṣugbọn mo ti gbiyanju lati sunmọ Ọlọrun, nigba-gbogbo, bi awọn iran naa ti maa n wa niyi, bi wọn ti maa n ṣẹlẹ. Awọn eniyan tilẹ maa n ju ohun ini wọn nu, ti wọn yoo si pe mi, ti wọn yoo bi mi lati gbadura si Oluwa, lati beere ibiti o wa. Bi ti Jesse ti o ju ibakasiẹ rẹ nu, awọn ọmọkunrin naa si wa wolii lọ, o si sọ fun wọn nipa bi ibakasiẹ naa ṣe ti pada wa sile, ati bẹẹbẹẹ lọ. Eyi tọna bẹẹ gẹlẹ. Ṣugbọn mo ti ri ọpọlọpọ eyi, ọpọlọpọ eniyan. Ti wọn ko si ni agbegbe yi - o ṣẹlẹ kaakiri agbaye, ṣe ẹ rii. O si maa n mu ki o rẹ eniyan pupọ. O n fi ọ si ipo kan nigba-gbogbo, titi ti iwọ yoo fi de ipo kan ...

19 Ohun to mu ki awọn ará bẹrẹ ẹkọ kan pe emi ni Jesu Kristi ti o pada wa niyi. A si mọ pe eyi yoo ya iṣẹ iranṣẹ naa pẹrẹpẹrẹ, yoo si mu ẹgan wa si ori Kristi ati ohun gbogbo, ṣe ẹ rii. Idi niyi ti mo fi ni lati mì wọn pupọ, ki wọn lee dẹkun siṣẹ bẹẹ kiakia, lati jẹki wọn o mọ pe iyẹn ki i ṣe ti Ọlọrun, nitori nigbati wọn ri otitọ Iwe Mimọ, wọn pada si ọdọ Ọlọrun, gẹlẹ, ṣe ẹ rii, kiakia. Iyẹn fihan pe Satani lo n gbiyanju lati ṣe ohun kan pẹlu awọn eniyan. Kristẹni tootọ ni awọn eniyan naa.

20 O si mu ki ọpọlọpọ wọn sọ pe, “Arakunrin Branham, a ni igboya pupọ si i ninu rẹ nisisiyi ju atẹyin wa lọ.”

Nitoripe, ṣe ẹ rii, ki ni - pẹlu ẹbun ti Ọlọrun ti fifun mi - ki ni ohun ti nko ba ti ṣe pẹlu iyẹn? Ki n fi gbogbo orilẹ ede si abẹ atẹlẹsẹ mi, tabi awọn eniyan. Ohun ti a n pe ni orilẹ ede ki i ṣe “ayika” ti a n ri nihin, awọn ohun kan ati omiiran. Mo n sọ nipa awọn Kristẹni, awọn onigbagbọ tootọ, awọn adun ... Ti a ba n sọ nipa orilẹ ede, a n sọ nipa awọn eniyan ti a ti tunbi, ohun ti a n sọrọ le lori niyi, “orilẹ ede.” Ki i ṣe gbogbo eniyan nihin ... Awọn ẹni eeri ati ẹgbin ti n gbe ninu aye. Awọn wọnyi kan jẹ erupẹ aye to pada wa ni. Mo n sọrọ nipa awọn atunbi Kristẹni, awọn eniyan ti i ṣe Kristẹni tootọ.

21 Mo n duro fun eniyan kan lati fo mọ mi lẹẹkansii nipa ohun kan. Ẹnikan tọ mi wa nigba diẹ sẹyin, o si wipe, “Idi ti Kristi fi tutọ silẹ, ti O si fi mọ amọ, ti O si fi mọ oju eniyan kan.” Pe, “Bawo ni o ti jẹ iwa idọti fun Un lati tutọ jade lati ẹnu Rẹ, bi o ti jẹ ohun ti ko ba imọ-toto mu lati tutọ sinu idọti, ki O si fi ṣe amọ, ki O si fi si oju eniyan.”

Mo wipe, “Ṣugbọn o pada wa, oju rẹ si riran.” Ṣe ẹ rii, ohun niyi. Ọkunrin yi kannaa ... Wọn ṣe agbekalẹ ibudo kan ti awọn eniyan ti n fi ihoho ara wọn han ni agbegbe mi - ṣe ẹ mọ, odo ti wọn ti n luwẹ. Ọkunrin naa si gba iwe iwọle fun ikọọkan awọn ọmọ rẹ lati lọ sibẹ, ki wọn o si lọ luwẹ ni odo naa. Oun ati iyawo rẹ pẹlu si lọ pẹlu, ninu odo naa. Ẹ jọwọ, ẹyin arabinrin mi, ṣugbọn nibiti awọn obinrin naa ti n luwẹ - nkan bi ọgọrun wọn, tabi igba, lojoojumọ - awọn obinrin, gbogbo iwa eeri ati ohun bẹẹ, ati awọn eniyan loni, ti wọn n fọ ara wọn sinu odo naa, wọn n fọ eeri ati ẹgbin ẹnu wọn sinu odo naa, wọn n gbe omi rẹ mi, wọn si n tu u jade. Mo

fẹ ki o tun ba mi sọ eyi lẹẹkansii, ṣe ẹ rii.

O wipe, "Ti Kristi ba wa loni, wọn o fi panpẹ ofin gbee nitori iwa ọ̀bùn ti O wu."

Eyi ti oun ṣe nkọ? Mo gbagbọ pe ẹ loye ohun ti mo n sọ. Wọn nlọ sinu odo naa, ọpọlọpọ wọn pẹlu oniruuru aisan - aisan àtọ̀sí, aisan miran bẹẹ, ati ohun gbogbo bẹẹ - nibẹ. Ti ẹ si n tutọ eyi jade lati ẹnu yin, ati ohun gbogbo bẹẹ, ti ẹ si n fọ ara yin nibẹ bẹẹ. Iyẹn jẹ imọ-toto lootọ.

22 Nitorina, akiika, ọjọ ti a n gbe ninu rẹ yi, arakunrin, arabinrin! Akoko ipadabọ Oluwa ti to! Ijọ ni ireti kan, eyi si ni ipadabọ Oluwa.

Koburu, nko lee dẹkun awọn nkan wọnyẹn. Ko si idi fun eyi. Bibeli ti sọ pe wọn yoo wa nihin. Nko lee dẹkun wọn. Ṣugbọn mo fẹ ki ohùn mi wa ni kika-silẹ ni ọrun pe mo ṣe atako rẹ, ni ọjọ idajọ. Mo sọrọ lodi si i.

Mo si gbagbọ pe Bibeli yi ni Ọrọ Ọlọrun. Lẹyinnaa, ko si ohun ti o ṣẹku ninu aye ti o lodi si i, ti o lee jẹ ikọsẹ siyin. Ṣugbọn Bibeli yi nihin, Oun ni otitọ, eyi ni Ọrọ Ọlọrun. Nisisiyi, ẹ jẹki a mu òbèlè wa, ki a si fi idakoro wa si ibi isimi Rẹ. A si lee tu ọkọ̀ wa lọ si ibomiran ni ọla, ṣugbọn ẹ jẹki a ni idakọro nisisisyi ki a si feti-si ohùn Baba wa ọrun bi yoo ti ba wa sọrọ nipasẹ Ọrọ Rẹ, a ni igbẹkẹlẹ ninu eyi, loni.

23 Ni aṣalẹ yi, ẹ ko ibeere kekeke ti ẹ ba ni jọ ... Bayi, ki i ṣe ibeere ti o lee pa ẹnikẹni lara. Ti ẹ bạ se bẹẹ ... Nko tilẹ ni dahun iru ibeere bẹẹ, ṣe ẹ rii. Ṣugbọn ohun kan tabi omiiran, bi ki a sọ pe, "Koburu, nisisiyi, ti mo ba ṣe ohun kan, njẹ Ọlọrun sọ pe ki a ṣe eyi?" Tabi, ṣe o mọ, ibeere kekere ti o wa ninu ọkan rẹ. Tabi, "A ni awọn ẹbun to n sisẹ pẹlu wa, Arakunrin Branham, ṣe ki a lo wọn lọna yi tabi lọna yẹn? Tabi, ibeere ti mo lee dahun ninu Iwe Mimọ, ṣe ẹ rii. Ẹ kọ ibeere kekere kan jade, inu mi yoo dun si eyi. Ti ko ba si, n o kan mu akori kan, n o si fi ba yin sọrọ laṣalẹ yi, bi Oluwa ba fẹ. Ọjọ Aiku niyi ...

24 Ni ọjọ Aiku to kọja, mo bẹrẹ si lọ si ile Arakunrin Cobble. Mo si gbọ ti agogo isin ijọ yi n dun, mo si rin lọ soke-sodo, ninu agbala naa. Nko lee faradaa, koju bẹẹ lọ. Nitorina, mo ni lati wa sihin.

Nitorina, ẹ jẹki a tẹri wa ba nisisiyi, ki a si ba Ẹlẹda wa sọrọ̀, lẹyinnaa, ninu gbolohun adura kan. Njẹ ẹnikẹni ni ẹbẹ adura Pataki kan? Na ọwọ rẹ soke ... Sọ ọ di mímọ̀. Ọlọrun mọ ohun ti o wa ni ọkan rẹ. Bayi fi ẹ̀bẹ̀ adura rẹ si ọkan rẹ.

25 Ọlọrun mimọ julọ, Iwọ ti O da ọrun oun aye nipa Ọrọ ẹnu Rẹ, nipa ero ọkan Rẹ, awa mbọ wa si iwaju Rẹ, nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa, lati fi ọpẹ fun Ọ fun ohun gbogbo ti O ṣe fun wa. A si dupẹ pupọ lọwọ Rẹ, Oluwa, ni owurọ yi, lati mọ ibiti a n duro si, lati mọ ipo ti a wa ni owurọ yi, ati itan akoko, ati igba to mbọ wa. Bi a ti n mọ loni nipa oore ọfẹ Ọlọrun pe a ti fọ wa ninu ẹjẹ Kalfari, ti a si ti pese wa pẹlu igbagbọ ninu ọkan wa lati pade Rẹ ti O ba de loni, ki a sọ pe, "Bẹẹni, wa Jesu Oluwa."

A si ri bi ẹṣẹ ti nkorajọ, titi ti o fi dabi ẹnipe eniyan n ṣubu labẹ ipá ẹṣẹ. Bi ọti mimu, tẹtẹ tita, agbere, ihoho, ati iwa eeri, irira ati ẹgbin ti awọn eniyan n ṣẹ, Ọlọrun, bi wọn ti n ... Bi wọn yoo ba wo o, Oluwa! Njẹ awọn eniyan ti wọn mura ni ọna yẹn ninu awọn aṣọ ẹṣẹ naa, ti wọn si bọ si oju popo bẹẹ, njẹ wọn loye pe awọn ko jẹ ohun miran yatọ si kokoro ati erupẹ, ti o jẹ ni nkan bi ọsẹ kan si asiko yi, idin lee jẹ ara naa ti wọn n pọnle? Njẹ wọn loye pe kokoro yoo jẹ ara awọn? Atipe, ọkàn wọn yoo wa lọhun titi ainipẹkun laisi Ọlọrun, laisi Kristi, laisi ireti, wọn n jin sinu irà ẹ̀ṣẹ̀ jin-jin, ki a lee ke wọn kuro lọdọ Ọlọrun nigbati O ba de? Iwọ Ọlọrun, fun wa ni awọn ohùn ikilọ, ki a lee ṣe ikilọ fun gbogbo ọkan niti ewu ti wọn n wọ inu rẹ lọ.

26 Wà pẹlu wa loni. Fun wa ni ọrọ ọgbọn, bi Solomọni ti sọ nigbakan ninu Iwe Oniwaasu, ki a lee jẹ ọlọgbọn ọmọle, ki a lee jẹ oluṣọ agbo yi. A si gbadura, Oluwa, pe bi a ti n wa awọn ọrọ ti a o sọ, pe wọn yoo jẹ aworan pipe ti yoo gba ọkan eniyan ti o jẹ alaini to bẹẹ gẹẹ nihin, ni owurọ yi.

A ko wa sihin, ki a si korajọ si abẹ ile olóoru yi ki eniyan lee ri wa, ṣugbọn a ti wa sihin nitoripe a fẹran Rẹ, ati nitoripe a n fẹ lati gbọ lati ọdọ Rẹ. Iwọ ni olufẹ ọkan wa ti a fẹran, a si n fẹ lati gbọ Ọrọ lati ọdọ Rẹ. A dupẹ fun ohun ti a ti gbọ. Yoo wa pẹlu wa fun igba pipẹ. Bayi fun wa ni ipin ti O ni fun wa loni, bi a ti n duro de Ọ si i. A beere fun eyi ni orukọ Jesu, ati nitori tiRẹ. Amin.

27 Bayi, ti ... [Arabinrin kan n fedefọ. Arakunrin kan n sọ itumọ ede naa.]

A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ìmọ́kànle ti a gba lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa. Wọn sọ fun wa, wọn si kilọ fun wa lati kiyesi awọn ọrọ wọnyi ti o ṣeeṣe ki Ẹmi Mimọ wa sọ loni. A ko si mọ ohun ti O ni fun wa, ṣugbọn a mọ pe ohun kan gbọdọ wa ti yoo mu tọ wa wa. Boya ibeere kan wa ni ọkan rẹ, ti Oun yoo sọ nipasẹ iwaasu naa. O lee sọ ọ nipasẹ iwaasu yi ni owurọ yi. O lee sọ ọ ni aṣalẹ yi ninu isin. Nibikan bi a ti nlọ ninu Ọrọ naa loni, O n gbiyanju lati, o da bi ẹnipe, O n kilọ fun ẹnikan lati gbá Ọrọ naa mu.

28 Bayi, ẹ ṣi Iwe Mimọ, ẹ jẹki a wọ inu Iwẹ Eksodu lọ, fun Ile Ẹkọ Ọjọ Isimi.

Nję ę ni isin iribọmi? [Arakunrin Neville sọ pe, "Rara, titi di agogo męfa irọlę yi."] Ko si. Isin iribọmi yoo waye ni agogo męfa irọlę.

29 Ę jęki a lọ si ori kętadinlogun Iwe Ęksodu, ki a bęrę lati ęsę karun, mo gbagbọ pe ęsę karun ati ikęfa ori kętadinlogun Iwe Ęksodu ni.

Oluwa si wi fun Mose pe, kọja lọ siwaju awọn eniyan naa, ki o si mu ninu awọn agbalagba Israęli pęlu rę, ki o si mu ọpa rę, ti o fi lu odo ni ni ọwọ rę, ki o si maa lọ.

Kiyesi, Emi o duro niwaju rę nibę lori okuta ni Horebu, iwọ o si lu okuta naa, omi yoo si jade ninu rę; ki awọn eniyan ki o lee mu, Mose sį se bęę ni oju awọn agbagba Israęli.

Bayi, ti n o ba pe eyi ni akori kan fun ile Ękọ Ọjọ Isimi, n o fę lati fi eyi şe akori fun ękọ ti owurọ yi: "Omi To N fi Igba-gbogbo wá Lati inu Apata."

30 A mọ pe Israęli ti n fi igba-gbogbo ję apęrę ijọ lati inu itan wa. Nitoripe, Israęli ję eniyan Ọlọrun titi ti wọn fi jade kuro ni ilę Egipti, lęyinnaa wọn ję ijọ Ọlọrun nitoripe a ya wọn sọtọ kuro lara aye yooku.

Nigbati a ba si ya wa sọtọ kuro lara aye yooku, nigbana a o di ijọ. Şugbọn niwọn igbati a ba ndapọ pęlu aye, a kii şe ijọ. Bayi, mo ni igbękęle pe iyęn wọ inu ọkan wa lọhun lọ, ti o si bọ si ibiti o yę. Şe ę rii, a ki i şe ijọ titi ti a o fi ya ara wa sọtọ kuro ninu aye. Ki a ya arawa sọtọ, ki a kuro laarin awọn eniyan naa, awọn ęni aimọ, ki a ma şe pęlu wọn mọ, ki a ma ba ję alabapin ęşę wọn. Maşe fi aidapọ dọgba pęlu alaigbagbọ, şugbọn ya ara Rę sọtọ kuro ninu awọn ohun aye.

Nigbati Israęli si wa ni ilę Egipti, wọn ję eniyan Ọlọrun. Nigbati a pe wọn jade, tabi ti wọn gba ipe-jade, ti wọn n jade wa, nigbana ni a pe wọn ni ijọ, nitoripe nigbana ni wọn ya ara wọn sọtọ kuro ninu aye yooku.

31 Ọrọ ti a n pe ni ijọ tumọsi "awọn ti a pe jade." Ęksodu, "Jade kuro laarin wọn. Ęnikọọkan wa, gęgę bi Kristęni, ni a ti ni ipe-jade ni aye wa. A ni akoko kan, nigbati a pe wa kuro laarin awọn ęgbę wa, a pe wa kuro laarin awọn eniyan ti a ti fi igba-kan dapọ mọ, ti a si di ęniyan ọ̀tọ̀, lati rin pęlu awọn eniyan ọ̀tọ̀ to n şe ni ọna to yatọ, ti o si n sọrọ ni ọna to yatọ. O ję ipejade kan ni aye wa.

Apęrę to dara ni Israęli fifun wa, niti igbati Ọlọrun pe wọn jade. Wọn ni ęksodu kan, wọn jade kuro laarin awọn eniyan aye, wọn si di orilę ede ti a ya sọtọ si Ọlọrun, eniyan ọ̀tọ̀. Wọn rin labę ojiji itę aanu. Wọn wa laaye, wọn si n rin nipasę ọwọn ina nla naa. Ọlọrun si mu wọn jade lati ilę Egipti si ilę ti O ti şeleri fun wọn.

32 Ati ninu ipejade yi, a fun wọn ni adari ęmi kan, adari ti i şe Mose, wolii nla ti a ta ororo le, ti i şe eniyan nla. O ję eniyan bi Ọlọrun, a bi i ni eniyan Ọlọrun. Ọlọrun pe e lati inu iya rę. Ani siwaju akoko naa, Ọlọrun yan an siwaju ipilęşę aye lati ję adari si iran naa, lati mu ipe-jade yi tọ awọn eniyan naa wa.

33 Nihin nigba-dię sęyin, mo ba awọn ọmọ kekere sọrọ ninu ijọ yi, mo sį se iwaasu kekere kan fun wọn ... Mọ se akawe kekere kan fun wọn nipa Jokębędi, bi o ti gbadura, oun ati Amramu, baba Mose, ti wọn n şe ohun kan nipa itusilę awọn eniyan naa. Amramu si ri iran Ọlọrun to n duro, tabi angęli kan to n tọka si iha ariwa, ti o si sọ ohun ti yoo şęlę fun un. A si bi Mose. Wọn ko si bęru aşę Ọba tabi ihalę rę̀. Wọn mọ pe ọwọ Ọlọrun wa lara Mose, koju bęę lọ. Bęę ni. Ohun to wu ki Ọba sọ, ohun to wu ki aye oşelu sọ, ohun to wu ki ohun miran sọ, wọn mọ pe ọwọ Ọlọrun wa lara Mose. Bęęni ęru ko ba wọn lati gbee si ori odò ọ̀nì, nibiti awọn ọ̀nì ti n jęun, ti wọn si n sanra lori awọn ọmọ Heberu, nibiti a ti fi wọn bọ awọn ọ̀nì nibę. Sibę a gbe Mose sinu apoti kekere kan, a si mu ki omi maa gbee lọ si aarin awọn ọ̀nì - laarin wọn - nitoripe wọn ko bęru ohunkohun. Wọn mọ pe ọwọ Ọlọrun wa lara Mose.

34 Koburu, bayi, ti a ba lee mọ ohun kan naa, pe adari wa nla-ni Ęmi Mimọ, Ọlọrun ti ran an. Oun si ni adari wa. Ohun to wu ki aye sọ, ati bi wọn ti lee fi ọ rẹrin ęlęgan, ki wọn o si fi ọ şe yęyę, a n tęle adari wa! Ọlọrun ran Ęmi Mimọ lati ję adari wa, şe ę rii. "Nigba dię si aye ki yoo si ri mi mọ. Sibę ęyin yoo ri mi, nitoriti Emi yoo wa pęlu yin, paapa ninu yin, titi de opin ilę aye." Bęęni adari nla wa wa pęlu wa, Ęmi Mimọ. Bayi a gbọdọ tęle adari yi ki a sį se bi O ba ti sọ pe ki a şe. Adari yi ko si lee mu wa kuro ni ipa ọna Rę laelae. Yoo pa wa mọ ni ipa Iwe Mimọ nigba-gbogbo. Şugbọn Oun ko ni lọ si iha kan fun ohun kan, ati si iha miran fun ohun miran. Yoo duro si ọna Iwe Mimọ tarata.

35 Mose si ni ojuşę lati ko awọn ọmọ Israęli jade, ki o si tęle wọn la Òkun Pupa ja, ati lati la Jordani ja, lọ si ilę ileri naa, kuro ni aginju. Ki i şe Ọlọrun lo kuro lori ila. Awọn eniyan naa lo kuro lori ila, eyiti o fa işoro. Nitorina, ę jęki a ronu lori awọn nkan wọnyi nisisiyi.

Mose ję adari ti a ta ororo le lori. Nikęyin, lęyin ti o ti fihan awọn eniyan naa, nipasę awọn işe ami ati awọn işę iyanu, eyiti Ọlọrun nikan lee şe ... O şe awọn işę ami ati işę iyanu wọnyi niwaju awọn agbaagba Israęli, ati niwaju Israęli titi ti a fi tęwọn lọrun pe Mose yi ni ęni ami-ororo naa ti a yan lati mu wọn kuro ni orilę

ede yi lọ si ilẹ rere naa, eyiti a ti ṣe ileri rẹ fun wọn. Lẹyinnaa, nigbati wọn ri awọn iṣẹlẹ nla wọnyi ti Mosẹ se ni orukọ Oluwa, wọn ṣetan lati tẹle e. O si ko wọn jade, o dari wọn la Okun Pupa ja, wọn si rin ni iyangbẹ ilẹ, ati sinu aginju, eyiti o tumọsi akoko idanwo.

36 Nigbati eniyan kan ba gba Kristi bi Olugbala rẹ, ohun gbogbo yoo maa lọ bi o ti yẹ. Ṣugbọn ki eniyan yi to wa si baptisimu Ẹmi Mimọ, o gbọdọ kọkọ ni akoko isọni-di-mimọ. O gbọdọ ni akoko idanwo ni aye rẹ̀. Gbogbo yin ni ẹ ni in. O ni akoko idanwo yi. “Gbogbo ọmọ ti o ba tọ Ọlọrun wa ni a o kọkọ lù, a o ba a wi, ti a o si nàá. Ti a ko ba si lee farada ibawi naa, nigbana, o fihan pe awa ki i ṣe ọmọ Ọlọrun,” Bibeli sọ bẹẹ. Ṣugbọn ti a ba lee farada ibawi naa, bi a ti mọ eyi pe “ohun gbogbo n siṣẹ pọ fun rere si awọn to mọ Ọlọrun,” nigbana ni a jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, O si fi Ẹmi Mimọ ṣe edidi wa titi di ọjọ idande. Ṣe ẹ rii, eyi ni ibawi naa. Idojukọ, awọn ohun ti a n la kọja. Israeli gẹgẹ bi afiwe wa ninu itan ni lati gba ibawi yi.

37 Bayi, nigbati wọn wa ni ilẹ Egipti, ti Ọlọrun si ran Mose, ti o si na ọpa rẹ, ti awọn kokoro eṣú ati kokoro ina si ṣú bo ilẹ, o na ọpa rẹ si oorun, oorun si wọ̀, o nàá si ori omi, wọn si dị èjẹ̀, eeṣe, Israẹli wa ni ilẹ Kenani ... Ni Gosheni, wọn n ni akoko ologo. Oorun ko wọ̀ nibẹ, bẹẹni arun naa ko kọ lu wọn. Eeṣe, wọn kan n ni akoko ologo ni.

Bi ẹyin pẹlu ti ṣe nigbati akọkọ gba yin la. Ohun gbogbo, awọn ẹyẹ nkọrin yatọ, bẹẹni gbogbo eniyan si jẹ adun. Ah, akiika, bi ohun gbogbo ti n dun nigbati a kọkọ gba yin la! Lẹyinnaa ti akoko idanwo de, ibawi naa, igba isọnidi-mimọ, ẹ n fọ ara yin mọ kuro ninu ohun aye, “ẹ n pa gbogbo idiwọ ti o rọrun lati so mọ yin ti.” Ẹyin ọkunrin nilati fi siga-mimu yin silẹ, ẹ fi ọti mimu yin silẹ, ẹ fi lilọ si ile tẹ́tẹ́ yin silẹ, gbogbo aisun ti ẹ n ṣe ni ile tẹ́tẹ́ ni ki ẹ fi silẹ. Gbogbo awọn nkan wọnyi, ẹ ni lati sọ ara yin di mimọ kuro ninu wọn, nipa igbagbọ ninu ẹjẹ Jesu Kristi - ẹ n fọ ara yin mọ. Ẹyin obinrin ni lati jẹki irun yin gun, ẹ jẹ ki aṣọ yin balẹ, ki ẹ si maa ṣe ni ọna ti o yatọ si bi ẹ ti n ṣe tẹlẹ. Akoko isọnidi-mimọ. Ni ọpọlọpọ igba ni wọn yoo ṣọ̀tẹ̀, wọn si n pada-sẹyin. Koburu, ọmọ Ọlọrun kọ lo n ṣe iyẹn, ṣe ẹ rii. Ọmọ Ọlọrun maa n wo Kalfari tarata, o si mọ pe eyi wa fun rere oun.

38 Lẹyinnaa, ni akoko naa, ibẹ ni iṣubu kuro nla ti wọ aarin awọn ọmọ Israẹli. Nigbati akoko ìsúdẹ̀dẹ̀ de, nigbana ni awọn eniyan naa bẹrẹ si ṣubu kuro lọdọ Ọlọrun, wọn lọ lati apa kan si ikeji. Lẹyinnaa ninu ọrọ ẹnu wọn, “Koburu, o wu wa ki o jẹ pe ilẹ Egipti ni a si wa. Ounjẹ fúlẹ́fúlẹ́ yi n ṣe ọkan wa laarẹ,” (ni ede miran, ti mo ba sọ nipa itan bayi) ohun ti wọn sọ niyi.

Bayi, ni akoko igba-lode, yoo ṣẹlẹ bẹẹ, “Ah, ni gbogbo aṣalẹ Ọjọru a o ṣe ipade adura. Ni gbogbo owurọ ọjọ Aiku, a o pada wa si ile ijọsin. Ki ni ohun ti a n gbọ? Ohun kannaa - oniwaasu naa dide, o si n waasu, a n kọrin, a n pada lọ si ile.” Ṣe ẹ rii, lẹyinnaa ẹ nlọ bi igbati ẹ wa loju iṣẹ. Ẹyin ki i ṣe olujọsin. Olujọsin nlọ sibẹ lati jọsin, lati fi ara Rẹ han niwaju Ọlọrun rẹ, lati yin Ọlọrun fun inu rere Rẹ. O si n di gbogbo Ọrọ Rẹ mu.

39 Bi iṣe ololufẹ. Ti iwọ ba nlọ pẹlu ọmọbinrin kan nitoripe o mọ pe ojuṣe rẹ ni, tabi ti o nlọ pẹlu ọdọkunrin kan nigbati o jẹ ọdọ (“Iya mi nfẹ ki nlọ pẹlu ọmọkunrin yi, ṣugbọn nko lee ba lọ botiwu-kori.”), iwọ ko lee ni anfani kankan ninu abẹwo rẹ̀ si ọ. Tabi, ti o ba jẹ ni ọna kannaa nipa ọdọbinrin kan si ọdọkunrin kan, tabi ọdọkunrin si ọdọbinrin. Ti o ba lọ pẹlu rẹ̀, yoo su ọ; Iya rẹ̀ nfẹ ki o lọ pẹlu rẹ nitoripe o jẹ iru ọdọbinrin ti iya rẹ fẹran. Ṣe ẹ rii, yoo su ọ - iyẹn ki i ṣe ọrọ ifẹ. Ṣugbọn iwọ ko bikita, iwọ ko fẹ ki a fọ ọ mọ, iwọ ko fẹ lọ lati ri i ... Eeṣe, o jẹ ohun buburu. Nigbati ọdọkunrin naa ba si mbọ wa lati ri ọ, akiika, iwọ yoo fẹ ki o lọ kiakia, maa lọ si ile rẹ.

Bakannaa ni o ri, nigbati iwọ ba sọ pe, “Eeṣe, njẹ o waasu fun igba pipẹ? Awọn nkan wọnyi ati ohun gbogbo nkọ?” Ṣe ẹ rii, iwọ ko si ninu ifẹ.

Ṣugbọn nigbati o ba di gbogbo Ọrọ naa mu nitootọ, bi Ẹmi ti fun yin ni ikilọ ni owurọ yi, ṣe ẹ rii ... “Didi gbogbo Ọrọ Rẹ to n jade mu,” o lee jẹ ohun ti O n ba ọ sọ niyi - didi i mu! Oun ni iye ainipẹkun, gbogbo Ọrọ Ọlọrun. O jẹ ohun ayọ lati lọ si ile ijọsin, labẹ ipo-kipo kan. Boya ooru mu, otutu mu, ko si iyatọ, boya awọn eniyan naa n binu, boya wọn n kùn, ohun to wu ki wọn o maa ṣe, o si jẹ ohun ayọ sibẹ lati gbọ Ọrọ Oluwa. Nigbana o wa ninu ifẹ pẹlu Kristi, ṣe ẹ rii, iwọ yoo maa fẹ lati lọ si ile ijọsin.

40 “Koburu, olufẹ, owurọ ọjọ Aiku niyi lẹẹkansii. Mo ro pe a ni lati wẹ awọn ọmọ, ki a si lọ si ile ijọsin. Akiika, o jẹ ohun to n su eniyan.” Ṣe ẹ rii, iwọ ko si ninu ifẹ.

Ṣugbọn ti iwọ ba wa ninu ifẹ lootọ, iwọ ko ni duro titi ti owurọ ọjọ Aiku yoo fi de, iwọ yoo fẹ lati lọ sibẹ pẹlu wọn ni ... Ati awọn eniyan Ọlọrun, wọn ko lee mu ọ binu. Eeṣe, arakunrin ati arabinrin rẹ ni wọn i ṣe. Bi mo ti maa n sọ, iwọ yoo gan bi ẹ̀kọ-yangan ti maa n gan ninu otutu. Ki i sàn, o maa n di papọ ni, ṣe ẹ mọ, o n le. Bayi, iyẹn jẹ akawe ti o kun fun igberaga, ṣugbọn mo n gbiyanju lati jẹki o mọ ohun ti mo n sọ, ṣe ẹ rii. Iwọ yoo di papọ. Bi ó ba ti n tutu si, bẹẹ lo n le si. Bi o ti yẹki o ri pẹlu wa niyi.

'Gbati ọrẹ aye ba kọ ọ,

Di I mu si i.

41 Pe a fẹran arawa ki i ṣe nitoripe a jẹ eniyan pataki, ṣugbọn Kristi ni a n fẹran ninu arawa, ṣe ẹ rii. O jẹ Ọlọrun ti O wa ninu agọ arawa ni a n fẹran. Bayi, a n fẹ lati wa papọ. A maa n kọ orin atijọ kan:

Awọn 'bukun ifẹ Rẹ

To so wa pọ ninu Kristi

Idapọ didun ta n jumọ ni

Ri bi idapọ t'Ọrun.

Ṣe ẹ rii, idapọ didun ta njumọ ni ri bi idapọ t'Ọrun.

Ni iwaju itẹ Rẹ,

La mu adura wa,

Ireti, ifẹ wa j'ọkan.

Itunu at'aniyan wa.

Ṣe ẹ rii? Bẹẹ ni, sa! Nigbati ẹnikan ba gba ibukun kan, inu gbogbo wa n dun nipa rẹ. Nigbati eniyan kan ba banujẹ, a ni ibanujẹ pẹlu rẹ. A fẹ ki gbogbo wa wa papọ. Bayi, bi o ti yẹki a wa niyi.

42 Bi o ti yẹki Israẹli ri niyi. Ṣugbọn o di ohun ajaga, “Ah, ounjẹ fulẹfulẹ yi, ounjẹ angẹli! Koburu, ki ni ohun ti a n gbadun nipa ounjẹ fulẹfulẹ yi? O ti ṣu ọkan wa. Ohun gbogbo si lodi. Ati manna atijọ yi to n rọ̀ silẹ nigbogbo aṣalẹ, eeṣe, o sàn fun wa lati maa jẹ garliki ati leeki ni Egipti.” Ṣe ẹ rii, ọkan wọn ko ṣetan fun irinajo naa.

Nigbati ọkunrin kan tabi obinrin kan ba bẹrẹ sį se awawi nipa lilọ si ile ijọsin, ti o ṣu wọn pupọ lati maa lọ si ile ijọsin, wọn ko ṣetan lati rin irinajo naa. Bẹẹ ni. Ohun kan kuna nibikan.

Ah, nigbati o ba fẹran Ọlọrun, ti o si n ronu pe iwọ nlọ si ọrun, ti gbogbo yin si n lọ papọ!

Idapọ didun ti n funi l'ayọ

Mo n simile Apa Oluwa

Ifayabalẹ at'itẹlọrun

F'awọn to n gbẹkẹle Oluwa

O sunmọ pupọ,

Mo n simile Apa Oluwa.

... A maa n kọ awọn orin.

A n barawa kẹdun,

A jọ nru ajaga wa

'Gba gbogbo si ni omije

'Kaanu nsan loju wa!

Gba t'aba ti pinya,

O jẹ ẹdun ọkan fun wa;

Ṣugbọn ọkan wa yoo si jọkan,

N'ireti p'a o tun pade (ni bi ipade adura miran).

Bẹẹni, Ṣa, a o wa pọ sibẹ ninu ọkan wa.

43 Bayi, ẹ n mura-silẹ fun irinajo naa, ṣe ẹ rii, ẹ ti ṣetan lati lọ si ilẹ ileri naa. Akoko idanwo, ibẹ ni ilẹ ewu - aginju naa, igba idanwo.

Israẹli, ni akoko idanwo rẹ̀, wọn bẹrẹ ija ati ìkùn-sínú laarin arawọn, wọn si n ṣe awawi lori ounjẹ ti wọn n jẹ, wọn si fẹ pada si ilẹ Egipti.

Lẹyinnaa, wọn bẹrẹ sị se awawi lori adari wọn. Ah, wọn n bẹru pe o n ṣì awọn dari. Lẹyin ti o ti fi ara Rẹ han wọn lati jẹ adari kan, ti Ọlọrun si ti fi idi rẹ mulẹ lati jẹ adari, “Koburu, boya a ti ṣe iṣe alakatakiti diẹ. Boya, a si ti kuna, ti gbogbo wa si ti lọ si ipa ọna ti o lodi.” Tabi ohun kan bẹẹ, ṣe ẹ rii. Wọn n sọrọ lodi si Ọlọrun ati lodi si Mose - Ọlọrun ati adari ti O yan.

44 Bayi, nigbati a de ipele kan, ti a ti n sọ pe, “Nko mọ boya Ọrọ Ọlọrun tumọsi eyi tabi bẹẹkọ. Nko si mọ nipa ”Ẹmi Mimọ. Mo n ṣiyemeji diẹ. Mo mọ awọn miran ti ko gba a.“ Koburu, maa lọ si Egipti, ṣe ẹ rii.

Ti iwọ ba ṣe ipinnu lootọ lati duro si oju ọna naa, duro ti adari rẹ, Ẹmi Mimọ, duro ti Ọrọ naa. Ti o ba si duro ti Ẹmi Mimọ, Oun yoo pa ọ mọ sinu Ọrọ naa. Bẹẹni. Yoo mu ọ rin oju ọna, ipa Ọrọ naa. Maṣe bẹru Rẹ. Ki yoo pa ọ lara rara; yoo ran ọ lọwọ nigbati o ba ni ifarapa. Yoo wo gbogbo ipalara rẹ san, Ẹmi Mimọ yoo ṣe bẹẹ.

45 Bayi, a rii pe ni oju ọna yi, lẹyin ti wọn ti ni eyi, wọn de ibikan ni Horebu. H-o-r-e-b-u, Horebu, lẹyinnaa ni a rii pe ... Ẹ jẹki a fọ orukọ naa si wẹwẹ. Ibẹ ni ... Orukọ ti a n pe ni Horebu tumọsi “ilẹ gbigbẹ” tabi ilẹ “aṣalẹ.”

Nigbati a ba si kuro ninu idapọ pẹlu Ẹmi Mimọ, eyi n mu wa wa si ilẹ gbigbẹ, aṣalẹ - nibiti ko ti si iye. Ohun gbogbo yoo ni ẹ̀gún lara. Ilẹ Aṣalẹ. Ẹ̀so ẹlẹgun pẹlu ipẹpẹ ara rẹ ni yoo maa wa nibẹ, njẹ ẹ mọ ohun ti iyẹn tumọsi? Iyẹn ni ewe kekere kan to sọwọn, ti ko ni omi kankan ninu. O kan maa n hun ara rẹ jọ, titi ti yoo fi gan. Nigbati o ba si ri eniyan kan bi eyi, boya o jẹ ọkàn ọwọn kan ti o yẹki a ti bu omi rin daradara, ti ko ba ti jẹ ewe tutu ti ko ba ti wa fun ohun kan. Ṣugbọn dipo iyẹn, o ti hun ara rẹ jọ, titi ti o fi gan, ti o n kọlu ohun gbogbo, ṣe ẹ mọ, o n wa àlèébù ẹlomiran. Ohun kanṣoṣo ti o nilo ni omi, koju bẹẹ lọ. O kan nilo isọji ni, tabi ki a fọ ọ wẹwẹ, itura lati ọdọ Oluwa wá. Yoo si ṣi ara rẹ, ti iwọ yoo ba fi i sinu omi.

46 Ṣugbọn awọn ti wọn n gbe ni ipo naa ni lati jiya pẹlu ipo ilẹ naa. Ati awọn ti wọn fẹ lati maa gbe ni iru ayika bẹẹ, nibiti ohun gbogbo ti jẹ ibinu ati ija, ati odi ati irunu bẹẹ, koburu, iwọ yoo kan maa gbe ninu inu ayika bẹẹ, koju bẹẹ lọ. Ṣugbọn a ko ni lati maa gbe nibẹ, ko ṣe pataki fun wa lati maa gbe nibẹ.

Bayi, Horebu yi ni ibiti inu Ọlọrun ti bajẹ si eniyan, nitoripe wọn ti rin de ibiyi, wọn si wa ninu ipo yi. Ọlọrun si mu wọn wa si ayika naa nitoripe wọn kọ lati rin ni oju ọna. Wọn yà kuro ni oju ọna, wọn ya si iha ọna yi. Lẹyinnaa, o mu ki Ọlọrun ṣe ohun kan ti o buru jai ... Eyi si mu ki Ọlọrun sọ fun Mose lati mu ọpa idajọ, eyiti o ti fi ṣe idajọ orilẹ ede naa, ki o si lu apata naa, lati mu omi jade wa.

Bayi, ẹkọ daradara kan wa nihin ti a o ba loye rẹ, ṣe ẹ rii. Ati nitoripe a ko bìkítà, ti a si ti so wa mọ ohun aye ati ohun bi eyi, eyi mu ki Ọlọrun mu idajọ aye, ki O si lu Ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo pẹlu rẹ ni Kalfari; ki a lee lọ ni ominira. Njẹ ẹ ri ohun ti mo n sọ?

47 Bayi, lati lee mu awọn eniyan wọnyi de ibi omi, lẹyin ti wọn de ibẹ, a fi ilẹ gbigbẹ yi ṣe Kalfari. Nibẹ ni Ọlọrun ti sọ fun Mose pe, “Mu ọpa naa ati awọn agbaagba, ki ẹ si lọ, Emi yoo si duro si ori apata naa niwaju rẹ.” Apata yi si ni Kristi. Mose, pẹlu ọpa ti o ti fi mu idajọ wa si ori orilẹ ede Israẹli, o mu ọpa yi kannaa, o si fi idajọ Ọlọrun lu apata yi, ṣe ẹ rii. O mu ẹṣẹ awọn eniyan naa sinu ọpa yi. Eyiti o yẹki o fi lu awọn eniyan naa. Dipo ki o lu awọn eniyan naa, o lu apata naa. Ati apata naa, nipasẹ iṣẹ iyanu Ọlọrun kan, O mu igbala wa, O mu omi wa fun awọn to n ṣegbe. O fi iye fun awọn to n ku lọ. Eyi si ni ohun ti Ọlọrun ṣe nipasẹ bi O ti mu ọpa idajọ Rẹ, ti O si ko ẹṣẹ mi ati tirẹ pẹlu, ti O fi wé ọpa yi ka, nigbati O yẹki O ti fi lu wa; ṣugbọn O fi lu Kristi, ti omi fi ti ara Rẹ jade wa, eyiti o tumọsi “Ẹmi.” Ẹmi Mimọ ti ara Rẹ jade wa lati fi iye fun wa. Bayi, a ni iye ainipẹkun. Bayi, Kristi ni apata naa. Bayi a fẹ kiyesi eyi ...

48 Mo ti ri ọpọlọpọ aworan ti awọn eniyan fi ọgbọn ori ya nipa apata yi. Mo ti ri ọkan ninu awọn apata yi. Mo ti ri ọkan ninu awọn aworan naa ti o gajulọ, nigba diẹ sẹyin, ni ibiti apata kekere kan n duro si ni ori oke kan. O si yẹki Mose ti lu apata yi, awọn ọmọ Israẹli si wa nibẹ pẹlu ife-omi, ti wọn n bu omi fun arawọn lati inu omi ti n sun jade lati inu apata yi. Bayi, ero ẹnikan niyi.

Ṣugbọn nigbati apata yi mu omi inu rẹ jade nibẹ, awọn eniyan ti o wa nibẹ ju miliọnu meji lọ, yatọ si awọn maluu, rakunmi, ati ohun gbogbo bẹẹ, ti wọn mu omi pupọ lati inu apata naa. Odo to n tu jade wa lati inu rẹ ni!

49 Bakannaa ni wọn ti gbiyanju lati mu Kristi, Ẹmi Mimọ naa, loni. “O jẹ omi kekere to n fọ́n jade.” Ṣe ẹ rii, iyẹn to lati mu ki eniyan gbagbọ pe Ọlọrun kan wa. Rara!

O jẹ omi ti o to, ti o si tun ṣẹku! Dafidi sọ pe, “Aago mi kun akunwọsilẹ!” O jẹ Ẹmi Mimọ to n tu-jade.

Awọn eniyan n bẹru rẹ. Awọn kan sọ pe, “Koburu, ẹru n ba mi diẹ pe emi yoo ṣe eyi tabi iyẹn, tabi ti mo

ba lọ jinlẹ jù. Mo lee fihan yin pe ẹnikan lọ jinlẹ jù." Ṣugbọn ẹ ko tọka si eyiti ko lọ jinna tó, ṣe ẹ rii. Awọn ti ko lọ jinna to nkọ?

50 Bayi, a ti ni awọn eniyan kan ti wọn wọ inu ẹran ara, ti wọn si gbe igbesẹ ti ko tọna (ki i ṣe Ọlọrun, ṣugbọn awọn eniyan naa) nitoripe wọn ko jẹ adari rere ati bẹẹbẹẹlọ, wọn ya si ipa ọna ti ko tọna, wọn ya sinu akata-kiti. Lẹyinnaa, gbogbo agbaye, eṣu tọka si wọn, "Ṣe ẹ ri eyi? Ṣe ẹ ri eyi?"

Koburu, ẹ jẹki n duro ni owurọ yi ki n si tọka si ọkẹ aimọye ni akoko yi ti wọn ko bẹrẹ rara. Awọn wọnyi nkọ? Ṣe ẹ rii, ẹ wo ipo wọn, ẹ wo eniyan bi Eichmann loni ... Wọn wipe, "Awọn onigbagbọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ ko ba ofin mu, wọn ko si ba ojú-mu, wọn ko si ni imọ iwe," ati bẹẹbẹẹ lọ. Ẹ wo Eichmann. Ọkan ninu awọn ti o ni imọ iwe to gaju lagbaye, o si̩ se iku pa awọn ọmọ ti o jẹ miliọnu mẹfa, obinrin ati ọkunrin - ọkàn miliọnu mẹfa. Ẹ ko fẹ tọka si eniyan bẹẹ.

51 Ṣugbọn awọn ará kekere ti ko lee kawe, boya ti wọn tilẹ n ṣi awọn orukọ kan pe ninu Bibeli, tabi boya ti wọn sọ ohun kan, tabi ti wọn ṣe ohun kan lodi, tabi ti wọn ṣe asiṣe kan, iwe iroyin yoo fẹ kọ jade nibi-gbogbo, ki o si sọ pe, "ko tọna lati gbẹkẹle wọn."

Lẹyinnaa ti a ko ba lee gbẹkẹle wọn, eeṣe ti imọ iwe - awọn ohun ọgbọn ori ti wọn ni loni? Ẹ wo Adolf Hitler. Ẹ wo awọn ọlọgbọn aye loni. Ẹ wo wọn! Òwe atijọ kan sọ pe, "Ìbí ko ju ìbí, bi a ṣe bi ẹrú, ni a bi ọmọ."

Ohun ti ẹ ni lati ṣe ni ki ẹ ni agbara nipasẹ Ẹmi Mimọ lati mọ ohun ti o tọna yatọ si eyiti o lodi, ki ẹ si mu ohun ti o tọna ati ohun ti o lodi.

52 Bayi, a rii pe Kalfari ti wọn ni yi, ti omi iye si tú-jade fun awọn eniyan.

Bayi, awọn eniyan miran ni in ni ọkan wọn ati ero wọn pe Israẹli mun omi, lẹyinnaa wọn ko awọn rakunmi wọn, wọn si so awọn ẹrù wọn si ara ẹsin wọn ati bẹẹbẹẹ lọ, ti wọn si ko awọn ọmọ wọn, ti wọn si rin irinajo lọ si ibomiran, ti wọn si fi apata naa sibẹ, to n sun omi jade. Iyẹn ko ri bẹẹ.

Apata naa n tẹle wọn, omi naa si n tẹle wọn. Bayi, ni ori kẹwa ti Iwe Korinti kinni, mo gbagbọ, ni ẹsẹ̀ kẹwa Rẹ, ẹ lee wo o, pe apata naa n tẹle Israẹli. Nibikibi ti wọn lọ lati igbana lọ, lati igbana lọ, apata naa n tẹle wọn, bẹẹ ni omi naa n tẹle wọn.

53 Iru afiwe arẹwa wo ni eyi ati ohun to rẹwa fun wa lati di mu, ati idakọro fun onigbagbọ loni ti o mọ pe apata naa ti a ti lu nigbakan, omi naa ti o tu jade lati Kalfari wa, o nlọ pẹlu wa nibikibi ti Kalfari wa, o nlọ pẹlu wa nibikibi ti a ba wa. Ah, akiika! Wọn ko ni de ibikan ti wọn o ti sọ pe, "Koburu, a ni omi ni ijẹta nibẹ." A ni omi ni oni, nihin, nitoripe Kristi ni apata naa, Kristi si jẹ ọkan naa ni ana, ati ni oni, ati titi laelae.

Ṣe ẹ rii, apata naa n tẹle Israẹli. Awọn kọ lo n tẹle apata naa; ṣugbọn apata naa lo n tẹle wọn. Amin. Israẹli nlọ ni ọna wọn. Ohun kanṣoṣo ni wọn ni lati ṣe. Eyi ni ki wọn o maa lọ ni ọna ti o tọ, ki wọn o maa lọ tarata si ilẹ ileri naa. Apata naa pẹlu omi inu rẹ n tẹle wọn. "... Apata naa n tẹle wọn! ..." Iwe Kọrinti kinni sọ bẹẹ, ni ori kẹwa. O dara. Apata naa ni Kristi.

54 Ọlọrun mu idajọ ti o yẹki awọn eniyan gba, O si fi si ori Kristi, O si lu U. Njẹ ẹ kiyesi pe àpá kan wa ninu apata lati igbana lọ? Apata naa ni àpá kan ninu rẹ, nibiti Mose ti lu U. Kristi pẹlu si ni oju àpá kan. Nigbati a lu U "A pa a lara nitori irekọja wa, ati nipa ina Rẹ ni a mu wa larada." Ati ninu iye Rẹ ni omi iye ti wa, eyiti a n gbadun loni!

55 Nisisiyi, fun wa lati ri iye yi gba ... Ẹ ranti pe iye Kristi n duro ti ijọ. Hallelujah! Ah, ti a ba lee fi ero ọkan wa sinu eyi fun iṣẹju mẹwa sii! Kristi ko fi ijọ silẹ. "Emi yoo wa pẹlu yin nigba-gbogbo, titi de opin aye." Awọn eniyan lo n fi Kristi silẹ, ki i ṣe Kristi lo n fi awọn eniyan silẹ. Awọn eniyan n fi i silẹ nipa aigbagbọ wọn. Wọn fi Kristi silẹ, ki i ṣe Kristi lo n fi awọn eniyan silẹ.

Israẹli fi iṣàn omi naa silẹ, ki i ṣe iṣàn omi naa lo fi Israẹli silẹ, ṣe ẹ rii. Nitoripe Bibeli sọ ọ kedere pe apata ati omi naa n tẹle Israẹli. O tẹle wọn! Nibikibi ti wọn ba lọ, Oun pẹlu n tẹle wọn.

56 Ah, n ó fẹ ni owurọ yi, ti a ba ni akoko, ki a si Bibeli wa si ori kinni Iwe Joshua nibiti O ti sọ pe, "Ibikibi ti atẹlẹsẹ yin ba tẹ, Emi ti fifun yin. Ibikibi ti iwọ ba lọ Oluwa Ọlọrun rẹ wa pẹlu rẹ. Maṣe bẹru ẹnikẹni. Mu aya rẹ le! Ibikibi ti o ba fi̩ esẹ rẹ le, Emi wa nibẹ pẹlu rẹ, ibikibi ti o ba jẹ." - Ọlọrun nlọ pẹlu Joshua.

Ọlọrun kannaa lo nlọ pẹlu ijọ ni owurọ yi. Ẹ jẹki a mun lati inu isun omi naa. Ibikibi ti atẹlẹsẹ yin ba tẹ, nibẹ Ọlọrun yoo wa pẹlu rẹ, lati bu omi rin ọ, ati lati fun ọ ni iye. "Emi yoo wa pẹlu rẹ nigba-gbogbo, ani titi de opin aye." Kristi, ọkan naa lana, ati loni, ati titi laelae. Ofin Ọlọrun.

57 Bi ẹ ti lee sọ pe, "Nigbana, Arakunrin Branham, eeṣe ti awa ko ṣe awọn ohun ti o yẹki a ṣe. Bawo ni yoo ti jẹ pe awọn ẹbun wa ati awọn nkan wa ninu ijọ ko ri bi o ti yẹki o ri? Eeṣe ti ijọ wa ko de ipele ti o yẹki o wa?"

Awọn eniyan lakoko idanwo, wọn ṣubu bi Israẹli pẹlu ti ṣe. Wọn ro pe Ọlọrun ti fi awọn silẹ.

Ṣugbọn, ẹ ranti eyi pe, apata naa ko fi Israẹli silẹ, Israẹli lo fi apata naa silẹ. Wọn gbagbe nipa bi apata naa ti n wa pẹlu awọn nigba-gbogbo. O wa nibẹ, O lọ pẹlu wọn titi de opin irinajo naa. O tẹle wọn. Ko jinna si wọn rara. O wa ni etigbọ wọn. Tabi, ko jinna si oju-ri wọn.

Bẹẹ pẹlu ni Kristi ko jinna si wa! O wa pẹlu ijọ loni, ko jinna si ibiti yoo ti gbọ wa. Ọpọlọpọ yin ti pada sẹyin, ẹ si ti ṣe ohun ti o lodi, ẹ si ti sọ ayọ naa nu, omi yin si ti gbẹ. O si wa ni arọwọ-to yin. O n tẹle ọ. O mọ gbogbo isiṣẹ rẹ. O mọ gbogbo igbesẹ ti o n gbe ati ohun gbogbo ti iwọ n ṣe. O n fẹ lati gbọ ki o pe Oun si oju-iṣe.

58 Ati fun isọji nla Pẹntikọsti ti a n ri loni, Ọlọrun n duro de yin lati pe Oun wa si oju-iṣe. Ko jinna si ohùn yin. Bi a tilẹ ti ṣe lodi ti a si ti dẹṣẹ si i, ti a si ti kọ ẹyin wa si i, ti a ti ṣe awọn ohun ti a ko gbọdọ ṣe pẹlu, sibẹ, O wa pẹlu wa. Kristi sọ pe Oun yoo wa pẹlu wa.

Bibeli sọ pe, “Omi naa tẹle awọn ọmọ Israẹli.” Nigbati oungbẹ n gbẹ wọn, wọn mọ pe omi naa wa ni tòsí wọn.

59 Bayi, a n dari awọn nkan wọnyi nipa ofin. Gbogbo agbekalẹ Ọlọrun ni a fi ofin gbekalẹ ... Ẹ jẹ̀ki a danu duro fun iṣẹju kan.

Ẹ jẹki a wo agbaye. Bi o ti n yi. Ni gbogbo wakati mẹrinlelogun lo n pari obiripo kan, o jẹ pipe. Ti ... A ko ti i lee, pẹlu gbogbo imọ-ijinlẹ wa, lati lee ṣe agogo ti o lee pa akoko mọ ni pipe. Lẹkọọkan, agogo ti o daraju ti wọn ti i ṣe, bi ọdun ti nlọ, o n le tabi ki o din ọpọlọpọ iṣẹju. Ṣugbọn aye ko kuna ri si bi o ti maa n ri ni iṣẹju ààyá kọọkan. O jẹ pipe to bẹẹ gẹẹ ti awọn onimọ-ijinlẹ loni, awọn to n wo ẹda ọrun, wọn lee sọ fun yin, bi oorun tabi oṣupa yoo ṣe re arawọn kọja, ni nkan bi ogún ọdun tabi ọgbọn ọdun si asiko yi. Nigbati o ba pari obiripo oru wakati mẹrinlelogun rẹ, o si n yi akoko rẹ yika obiripo naa fun akoko igba kan, ko padanu iṣẹju aaya kan. Hallelujah! O jẹ pipe, nitoripe o n yi nibamu pẹlu ofin Ọlọrun.

60 Wọn mọ igbati ikun omi yoo lọ, iṣẹju ti yoo ṣẹlẹ gẹlẹ, nitoripe wọn mọ igbati oṣupa yoo wọ̀. Ọlọrun si ti fi ohun gbogbo si ipo rẹ nipa ofin. Nigbati oṣupa ba si wọ, ikun omi naa yoo si lọ silẹ pẹlu rẹ. Nigbati oṣupa yẹn ba yọ jade, iji òkun n dide pẹlu rẹ. Wọn si mọ gẹlẹ nipa akoko, igbati oṣupa yoo wọ̀. Wọn lee fi si inu Kalẹnda fun ọpọlọpọ ọdun ti ko tii de, wọn yoo si sọ iṣẹju ti iji òkun naa yoo bẹrẹ si lọlẹ. Dajudaju, nitoripe ọna ti oṣupa n gba lati wọ̀ niyi, nitoripe a fi ofin Ọlọrun gbe e kalẹ.

61 Mo n duro si eti odo nla Michigan. Mo si lọ si odo nla Superior, nigbati mo nlọ si orilẹ ede Canada, odo nla naa. Mo si duro sibẹ, mo si ro o pe “Ibusọ melo ni eniyan yoo rin lati la odo nla yi ja?” Lẹyin ti mo la odo nla Michigan ja ... tabi, odo nla Superior, n o wa si Michigan, odo mejeeji fẹẹ jẹ iwọn kannaa. Ati si ibẹ, lati odo nla Superior si odo nla Michigan. Lati odo nla Michigan si odo nla Ontario, ati ti Huron, ati gbogbo wọn lapapọ. Iye àgbá omi ti o dara lọna aimoye biliọnu melo ni o wa ninu odo nla naa!

Ati ni ilu Nefada, ni ilu Arizona, ati ni ilu Mexico Tuntun, ni iha ila-oorun Kalifornia, ni aimọye sarè miliọnu ilẹ wa, ilẹ to n jona ti o si lọra wa, ti omi naa ba lee sàn de ori ilẹ naa, orilẹ ede yi lee bọ́ agbaye, laisi eniyan kan ti ebi n pa wa, ti wọn yoo si ni ọpọlọpọ ounjẹ lati da sinu òkun. Bẹẹ ni! Aimọye miliọnu sarè ilẹ ti yoo hu ọpọlọpọ miliọnu iṣu-ànàmọ́, ati kabbeji, ati erèé, ati lettusi, ati radisi, ati ṣeleri ati kukumba, ati iru eso miran - ilẹ naa yoo hu awọn eso wọnyi. Omi ni o nilo.

62 Omi naa si niyi nihin; ilẹ niyi nihin. Bayi a lee ri i, a si mọ pe yoo siṣẹ nitoripe a lee dan omi naa wo, ki a si ri i pe omi to dara ni, ki a sị se ayẹwo ilẹ, ki a rii pe o lọra. Bayi, gbogbo ifẹ ti a ni lọkan wa nipa nkan wọnyi ko lee mu wọn wá papọ. Ṣugbọn ofin kan wa, ofin naa si ni ofin láálá to ròkè. Bayi, ti a ba lee ṣe nibamu pẹlu ofin yi, a lee bu omi rin gbogbo ilẹ naa, a o maa mu omi lati inu odo naa, a o si maa bu omi rin in. Ṣugbọn a o ni lati siṣẹ nibamu pẹlu ofin láálá to ròkè. A ko lee fẹ ẹ lasan. A ko lee ke gbàjarè lasan. A ko lee ke jade lasan. A ni lati ṣe e nibamu pẹlu ofin laala to roke, lati lee mu ki omi naa wa si ori ilẹ naa. Ọlọrun fi ohun gbogbo sinu ofin kan.

63 Nihin, mo n ronu, nko mọ boya mo ti sọ eyi fun yin tẹlẹ tabi rara. Mọ wa ni ilu Kentucky, mo n ṣe ọdẹ ọkẹrẹ pẹlu Arakunrin Wood ni nkan bi ọdun kan sẹyin. Awọn ọkẹrẹ si sọ̀wọ́n, bẹẹni a si lọ si ile arakunrin kan lati mọ boya a lee ṣe ọdẹ ni ayika rẹ. Ọkunrin kan ti o ni ọpọlọpọ sarè ilẹ, ni ori ilẹ yi, ọpọlọpọ igi nla lo wa. Ṣugbọn Arakunrin Wood sọ fun mi pe keferi ni ọkunrin naa, alaigbagbọ ni. Bẹẹni o sọ pe, oun mọ ọKunrin ti a n sọ yi, tabi baba rẹ lo mọ ọn, yoo si lọ lati beere lọwọ ọkunrin yi, ti o ba lee gba a laaye lati lọ ṣe ọdẹ lori ilẹ rẹ.

A wa ọkọ́ lọ si ọdọ ọkunrin naa. Oun ati ẹlomiran, awọn mejeeji jọ wa ni ẹni ọdun aadọrin ati soke, wọn n joko si abẹ igi apu. Ọgbẹni Wood si tọ ọkunrin yi lọ, o si wi fun un pe, “Njẹ emi lee ṣe ọdẹ diẹ ni ori ilẹ rẹ?

O si wipe, “Koburu,” pe, “O dara.” O wipe, “Inu ẹbí Wood wo ni iwọ ti wa? Ṣe ọmọ Jim Wood ni ọ?”

Arakunrin Wood wipe, “Bẹẹ ni.”

Ọkunrin naa si wipe, “Koburu, olootọ eniyan ni Wood baba rẹ i ṣe,” ati bẹẹbẹẹ lọ. O wipe, “O lee dẹ̀gbẹ́ nibikibi ti o ba fẹ lori ilẹ mi. Mo ni ọgọọgọrun sarè nihin. Ran ararẹ lọwọ. Lọ si aarin awọn igi naa, ibikibi ti o ba fẹ lọ. Ni imọlara pe ile rẹ ni o wa.”

Mo joko sinu ọkọ̀ nitoriti mo ro pe keferi ati oniwaasu ko ni lee sọrọ pọ daradara, ti a ba fẹ tọrọ oju-rere keferi naa.

64 Lẹyinna, lẹyin igba diẹ, Arakunrin Wood sọ pe, “Koburu, bayi, oluṣọ-agutan mi wa pẹlu mi. Mo ro pe yoo dara fun un lati wa?”

Ọkunrin arugbo yi si wo yika nibiti ó wa, ó si wipe, “Wood ṣe iwọ n sọ fun mi pe o ti rẹ ara rẹ silẹ to bẹẹ gẹẹ ti o fi ni lati maa lọ kiri pẹlu oniwaasu kan?”

Bẹeni mo ro pe lẹyin eyi, o dara ki n jade kuro ninu ọkọ. Bẹẹ ni mo jade kuro ninu ọkọ naa, mo si ba ọkunrin naa sọrọ fun igba diẹ. O si jẹki n mọ kiakia pe oun ko nilo oniwaasu, nitoripe o ro pe wọn n sọ nipa ohun kan ti wọn ko mọ.

O wipe, “Wọn kan n sọ ohun ti wọn ko mọ ni.

O wipe, “Wọn kan n sọ ohun ti wọn ko mọ nkankan nipa rẹ ni. Koburu, ”o wipe, “nigbati eniyan kan ba ba mi sọrọ, mo fẹ ki o mọ ohun to n sọrọ le lori.” Bayi, iyẹn jẹ ọgbọn-ori daradara. ọgbọn-ori rere ni eyi. O wipe, “Bayi, ti eniyan kan ba ba mi sọrọ, nko fẹ ki o sọ nipa ohun kan tabi omiiran, irori lasan, ti ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Mo fẹ ki o sọ ohun kan ti o mọ nipa rẹ.” Koburu, mo bu ọla fun iyẹn. Mo bọwọ fun eyi nipa baba arugbo naa.

Bẹẹni mo sọ pe, “Koburu, lootọ, ẹnikọọkan ni ẹtọ si èrò tirẹ.”

65 O si wipe, “Oniwaasu kan wa si orilẹ ede yi ni ọdun diẹ sẹyin, ti o ṣe ipade ni agbegbe Action.” O si wipe, “Oniwaasu yi ni aṣalẹ ọjọ kan, bi o ti jẹ ajeji ni orilẹ ede yi, o sọ fun obinrin kan to n joko sinu apejọpọ rẹ, pe, 'Iwọ ni aṣọ inuju kan ni apo rẹ. Iwọ si ni Iyaafin Lagbaja ati tamẹdo. Iwọ si ni arabinrin kan ni ẹba oke nihin, orukọ rẹ ni Lagbaja ati tamẹdo. Arun jẹjẹrẹ ti n pa a ku lọ, jẹjẹrẹ inu ifun.' O si wipe, 'Mu aṣọ inuju yi, ki o si fi lee arabinrin rẹ lara, o si wi fun un pe bayi ni Oluwa wi, oun ki yoo ku, yíyé ni yoo ye.”

O wipe, “Obinrin yi kannaa jẹ ọrẹ idile mi.” ... O wipe, “Obinrin yi, emi ati iyawo mi ti lọ si ile rẹ ni owurọ ọjọ naa ... a duro ti obinrin yi. Aisan rẹ si buru jọjọ, awọn dokita ti pa a ti fun igba pipẹ. O buru to bẹẹ gẹẹ ti a fi ni lati gbee si inu ohun kan, a gbe e soke si ori ibusun, a n gbe e pada, a n yi i sinu ohun naa, ipo rẹ buru jọjọ.” O wipe, “Ni asalẹ ọjọ kan nibẹ, igbe kan jade wa bi ẹnipe ... ẹnikan ku.”

66 Ben wa nibẹ pẹlu aṣọ inuju naa, ti o mu lọ sibẹ. Mo gbagbọ pe iwọ ni ẹni naa, ṣe bẹẹ kọ arakunrin? Arakunrin Ben ni o wa nibẹ, o n mu aṣọ inuju naa, nitoripe oun lo mu obinrin naa lọ sibẹ.

O si wipe, “Ni owurọ ọjọ keji, o n jẹ eso apu dindin!” O si wipe, “Kọ se iṣẹ ti ara rẹ nikan loni, ṣugbọn ti alabagbe rẹ pẹlu, ara rẹ ya patapata.” O wipe, “Bayi, mo ti maa n ro o. Ti mo ba lee ri oniwaasu naa, o mọ ohun to n sọ - ” Pe, “N o fẹ lati ba a sọrọ.”

Arakunrin Wood wo mi, emi pẹlu si wo o. A duro sibẹ pẹlu aṣọ wa ti o ti dọti, ti a si ti làágùn sii, ti o kun fun eeri, a ti n wa ninu igbo, ẹ̀jẹ̀ ọkẹrẹ si wa ni gbogbo ara wa. Bẹẹni mo sọ pe, “Koburu,” Mo wipe, “Ṣe iwọ n sọ pe ti iwọ ba lee ba ọkunrin yi sọrọ, yoo sọ fun ọ bi o ti ṣe eyi?

O wipe, “Bẹẹni, sa, ohun ti mo n sọ niyẹn.”

Mo wipe, “Koburu, ohun daradara ni eyi.”

67 Mo n jẹ ọkan ninu awọn eso apu rẹ. Ewe wọn ti n pọn diẹdiẹ, ṣe ẹ mọ, ni akoko otutu, ni Oṣu Kẹjọ. Bẹẹni mo mu eso apu kekere yi, mo si n jẹ ẹ. Mo si wipe, “Eso apu yi dara pupọ.” Mo wipe, “Fun ọdun melo ni igi naa ti wa nihin?”

“Ah,” O wipe, “Mo ti gbin igi yi lati nkan bi ọgbọn ọdun si ogoji ọdun sẹyin, tabi ohun bẹẹ.”

“Bẹẹni, sa.” Mo wipe, “N o fẹ lati bi ọ ni ibeere kan.” Mo wipe, “Bawo ni, ni orilẹ aye yi ... Mo ti ri awọn eso apu naa to n jabọ lati ori igi yẹn, awọn ewe rẹ si n rẹ silẹ, a si wa ni aarin Oṣu kẹjọ.” Mo si wipe, “A ko tilẹ tii ni otutu. Ko ti i si ọyẹ́ tabi ohun kan, sibẹ, awọn ewe naa n rẹ silẹ lati ara igi naa. Eeṣe ti o fi ri bẹẹ?”

O wipe, “Oje ti fi igi naa silẹ.”

“Ah.” Mo wipe, “Nibo ni o lọ?”

O wipe, “Inu gbongbo.”

Mo wipe, “Bawo ni yoo ti pẹ to nibẹ?”

O wipe, “Titi di igba iruwe.”

Mo wipe, “Lẹyinnaa ni yoo pada wa, yoo si ru ewe tuntun fun ojiji, ati awọn eso apu tuntun fun jijẹ?”

O wipe, “Bẹẹ ni. Bẹẹ gẹlẹ ni.”

68 Mo wipe, “Koburu, mo fẹ beere ohun kan lọwọ rẹ, sa. Iwọ n sọrọ nipa awọn eniyan wọnyi ti ko mọ ohun ti wọn n sọrọ le lori.” Mo wipe, “Njẹ iwọ lee ṣalaye ọgbọn ti o sọ fun oje naa lati fi igi silẹ? Ti o ba duro sibẹ ni akoko otutu, igi naa yoo ku [Otutu naa yoo pa a. Iru iye wa ninu oje naa.]” Bẹẹni mo sọ pe, “Yoo ṣe iku pa igi naa. Iru ọgbọn wo lo mu ki oje naa kuro lara igi naa, ti o fi lọ sinu gbongbo. Ti o si duro sibẹ titi di akoko iruwe, lẹyinnaa ni yoo pada wa lati so eso apu pupọ si i?” Mo wipe, “Bu omi sinu ike kan, ki o si fi kọ òpó kan, ki o si ri i boya yoo pada lọ si isalẹ òpó naa ni Oṣu kẹjọ, ki ó si pada wa ni igba iruwe.” Mo wipe, “Ofin kan wa, ofin iṣẹda kan wa. Ọgbọn kan lo n sakoso ofin yi. Ki i ṣe iyẹn nikan, ṣugbọn ọgbọn yi kannaa ni lati dari ofin kannaa ti o mu ki oje naa lọ si isalẹ ninu gbongbo igi naa, ki o si pada wa.”

O wipe, “Nko ro nipa iyẹn ri.”

Mo wipe, “Ti iwọ ba lee mọ ọgbọn ti o mu ki oje naa lọ si inu gbongbo igi naa lati ara ẹka, ki o si pada wa, ọgbọn kannaa lo sọ fun mi nibẹ, ni aṣalẹ ọjọsi, pe, 'Lọ, ki o si fi aṣọ inuju naa si ara obinrin yẹn.'

O wipe, “Iwọ ni oniwaasu yẹn?”

Mo wipe, “Bẹẹni, ṣa, emi ni.”

69 Ni ọdun to kọja ti mo lọ sibẹ (o ti lọ), nigbati opó rẹ n joko si ori ijoko kan, to n bẹ èpo lara apu, ti o ka lara igi kannaa, Arakunrin ... Wọn kọkọ fẹ le wa pada, wọn ko mọ ẹniti a jẹ. Mo si lọ lati sọ fun obinrin naa nipa rẹ, pe a gba ifọwọsi lọwọ ọkọ rẹ, a si sọ fun un nipa rẹ. O wipe, “O ṣe ijẹwọ Kristi lẹkunrẹrẹ ki o to ku.”

Ṣe ẹ rii, ki lo n mu ki igi naa ṣe bẹẹ, ọgbọn wo lo n mu ki oje naa sa lọ si isalẹ igi naa? Ofin kan ni. O jẹ ofin ti Ọlọrun ti fi si ipo ti oyẹ. Ofin naa si ni ofin Ọlọrun ti yoo sakoso awọn ẹda Rẹ. Amin!

Ṣe ẹ mọ, nko bikita bi ẹ ti ke jade to, ti ẹ si sọ pe “... Oorun ko ni ran nigba ẹ̀rùn yi,” yoo ran botiwu-kori. Botiwu ki ẹ sọ pe, “Nko ni jẹki aṣalẹ wa,” Yoo wa, botiwu kori - nitoripe ohun ti a n gbe ninu rẹ yi ti a n pe ni aye, a n dari rẹ nipa ofin Ọlọrun.

70 Bayi, ẹyin arakunrin ati arabinrin, mo fẹ beere ohun kan lọwọ yin. Bi a ba ti tunwa bi nipa Ẹmi Ọlọrun ... Ọlọrun ko ni ibiti o ṣe ailera tabi abala ti o lokun - O jẹ Ọlọrun lapapọ! Ti iwọ ba si ni Ọlọrun tó ninu rẹ titi ti o fi jẹ ojiji lasan, iyẹn ni agbara ti o to lati da aye titun. O jẹ agbara ti o tó lati ṣẹda oṣupa titun ati agbekalẹ titun. Ọlọrun ni, O si lagbara! Ati nisisiyi, gbogbo onigbagbọ nihin ni iye ainipẹkun, eyitiṣe Ẹmi Ọlọrun ninu rẹ - agbara ti o tó lati ji oku dide, ti yoo mu alaisan larada, ti yoo fi obiripo si ipo rẹ. Ṣugbọn ofin kan lo n dari rẹ. Ẹmi naa ti o wa ninu yin, ẹjẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Olọrun. Ẹmi kannaa ti o ni ninu rẹ yoo gbe ọ dide ni ọjọ ajinde.

71 Jesu, nigbati O wa si ori ilẹ aye nihin, nigbati O ku, ọkan Rẹ kọja lọ si ọrun apadi, O si waasu si awọn ẹmi ti o wa ni igbekun, awọn ọkan ti o wa ninu igbekun ti wọn ko ronupiwada ni ọjọ Noah ti Ọlọrun ṣe suuru fun, fun igba pipẹ. Agọ ara Rẹ lọ sinu iboji. Ṣugbọn siwaju iku Rẹ, O fi Ẹmi Rẹ le Ọlọrun lọwọ. Ẹmi Rẹ tọ Ọlọrun lọ, Ọkan Rẹ lọ si ọrun apadi, agọ ara Rẹ si lọ si iboji. A ko si gba Jesu làyé lati jinde titi ti a fi mu Iwe Mimọ ṣẹ. Ko lee pada wa nitoripe O ni lati wa ninu iboji fun ọ̀sán mẹta ati oru mẹta. Ṣugbọn nigbati a ti mu gbogbo Iwe Mimọ ṣẹ, a ja ẹ̀wọ̀n naa; Ẹmi Rẹ bale Ọkan Rẹ, Ọkan Rẹ wọ inu ara Rẹ lọ, O si jinde pada.

72 Nigbati a ba si ku, ọkan wa yoo lọ si abẹ pẹpẹ Ọlọrun, ibiti mo ni anfaani lati ri ni owurọ ọjọ diẹ sẹyin, bi mo ti mọ, ninu iran naa, ninu eyiti Bibeli sọ pe Ẹmi wa yoo tọ Ọlọrun ti O fifun wa lọ, agọ arawa yoo si pada sinu erupẹ ilẹ. Ṣugbọn ni ọjọ kan, nigbati Iwe Mimọ ba wa si imuṣẹ, a o tu ẹmi wa silẹ lati ọdọ Ọlọrun wa, yoo wọ inu ọkan wa, ọkan yoo si wọ inu ara. Agbara ti yoo si gbe wa dide ti wa ninu wa nisisiyi! A wa ninu awọn ọrun nisisiyi. A ti wa ninu agbara ajinde.

Ti ko ba si ofin kankan si eyi, awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun yoo ṣe ẹda aye kan ti wọn yoo lọ lati maa dá gbe ninu rẹ. Agbara naa wa ninu yin lati ṣe e. Ti iwọ ba ni agbara Ọlọrun ninu rẹ bi o ti wu ki o kere

to, o ni agbara lati ṣe e - Ọlọrun lee ṣe ohun gbogbo. Ṣe ẹ ri ohun ti mo n sọ? Agbara naa ti o wa ninu yin yoo ṣe ẹda ... Ẹ lee pe aye kan jade, ki ẹ si lọ gbe ninu rẹ. Hallelujah! Ohun niyi.

Agbara ti o wa ninu ijọ nisisiyi niyi, ṣugbọn ofin kan lo n dari rẹ. Ofin naa ki i ṣe ki eniyan maa pa awọn ofin kan mọ. Ofin igbagbọ ni. Jesu sọ pe, "Ohun gbogbo lo ṣeeṣe fun awọn ti o gbagbọ." Ti o ba si gbagbọ, ohunkohun ti Ọlọrun ba si dari ọkan rẹ lati gbagbọ, ohun naa ni tirẹ. Ibikibi ti atẹlẹsẹ rẹ ba tẹ nipa igbagbọ, Ọlọrun yoo fifun ọ. Amin! Tirẹ ni, ini rẹ ni, ti o ba lee ri kọkọrọ si ofin igbagbọ yi ti o ṣilẹkun rẹ̀ fun ọ. Ṣe ẹ ri ohun ti mo nsọ? A n dari agbara naa nipa ... Ti iwọ ba jẹ ọmọkunrin Ọlọrun, ti o ba jẹ ọmọbinrin Ọlọrun, iyẹn ko lee fi ọ silẹ. O wa pẹlu rẹ nigba-gbogbo. Ṣugbọn igbagbọ rẹ n kuro nibẹ, sibẹ, o wa nibẹ. Hallelujah!

73 Nigbati a ba gba ọ la, Ọlọrun fun ọ ni igbagbọ lati dide kuro ninu ẹgbin aye. Igbagbọ rẹ bori ohun aye. Ki ni igbagbọ rẹ? Igbagbọ ti o ni ninu ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun ọ, lati mu ọ jẹ ọmọkunrin Ọlọrun. Iwọ yoo fi irọ pipa silẹ, iwọ yoo dẹkun ole jija, iwọ yoo fi ọti mimu silẹ, nitori igbagbọ rẹ mu ọ ta-yọ rẹ. Amin. Ti iwọ ko ba ṣe bẹẹ, iwọ ko ni igbagbọ kankan. "Nipa igbagbọ ni a gba yin la nipa ore-ọfẹ."

Bi o ba ti lee lo igbagbọ rẹ ni yoo sọ odiwọn agbara ti iwọ lee ni, nitori ninu rẹ ni agbara lati da ọrun oun aye n gbe. Ọlọrun n gbe inu rẹ, ẹ si jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun. Amin. Ohun ni yi. Ṣugbọn igbagbọ rẹ ni. Jesu sọ pe, "Ki o ri fun ọ, gẹgẹ bi igbagbọ rẹ. Ti iwọ ba gbagbọ, ohun gbogbo lo ṣe e ṣe. Lootọ, ni mo wi fun yin, ti ẹ ba sọ fun oke yi, 'Ṣidi, ki o si lọ,' ti ẹ ko si ṣiyemeji, ṣugbọn ti ẹ gbagbọ pe ohun ti ẹ sọ ..."

74 Nigbana, iru eniyan wo ni o yẹki a jẹ, ti a ba n ni igbagbọ ninu Kristi Olurapada to n gbe ninu wa yi, apata naa ti a lu, ti ko fi igba kan fi ijọ silẹ? "Emi wa pẹlu yin nigba-gbogbo, titi de opin aye," apata to n tú omi igbala ati agbara jade, to n ṣàn wa lati kalfari si inu ijọ, to n fi igba-gbogbo wa; ifarahan Ọlọrun to n fi igba-gbogbo wa nitosi, omi iye nla to n san lati inu apata ti a lu, to nlọ pẹlu wa ni irinajo wa.

75 Israẹli sọ igbagbọ rẹ nu. Wọn ya kuro ni oju-ọna naa. Wọn bẹrẹ siṣe ifẹkufẹ si ohun ara. Ti wọn ba ti duro ti igbagbọ ti wọn si n gbagbọ pe Ọlọrun yoo mu awọn de ilẹ naa, kì ba tí si ohun kan ti yoo de wọn lọna. Wọn ti ṣi okun, wọn pe iyọnu sọkalẹ sori awọn ọta wọn, wọn ti pa awọn ọta wọn si ẹhin wọn, wọn si ti rin lọ si ilẹ naa, sibẹ wọn ko lee ni igbagbọ lati de ilẹ ileri naa.

Joshua ati Kalẹbu ni igbagbọ naa. Wọn wipe, "Awa ni agbara ju bẹẹ lọ lati bori ohunkohun ti yoo wa si iwaju wa."

Eyi ni iṣoro ti ijọ ni. A lee ṣẹgun gbogbo aisan. A ni agbara naa ni inu wa. A jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun, ko si ohun ti o lee duro niwaju wa. Ohun kanṣoṣo ti O fẹ, O n fẹ lati ri eniyan ti yoo gba ileri Rẹ gbọ, ti yoo gba ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun un gbọ. Ki i ṣe pe a o jẹ aṣẹgun; a ti jẹ aṣẹgun naa! Ifarahan Ẹmi ti o wa laaye titi laelae si wa pẹlu wa. Amin! Ohun niyi.

76 Ohun ti mo n sọ ni owurọ yi niyi, omi to n fi igbagbogbo wá lati inu apata. Omi naa to n fi igba gbogbo wa ninu apata wa nihin lọwọlọwọ, omi to n fi igbagbogbo sun jade, lati inu apata naa ti a lu ni Kalfari. Nigbati Ẹmi Mimọ fi i silẹ ni Kalfari, ti O si pada si inu ijọ ni ọjọ Pẹntikọsti, Ẹmi Mimọ naa wa nihin ni owurọ yi, O si ṣe ileri kan fun wa.

Idi niyi, O n rin niwaju awọn alaisan, nigbati O fi aṣẹ fun mi ni ọjọsi, mo gba a gbọ - Ọlọrun sọ bẹẹ! Bi iran ti n wá niyi. Ọlọrun ṣe ileri rẹ! Ọlọrun ko lee parọ!

77 Gba a gbọ! O ni lati gba a gbọ. Ohun kan gbọdọ wa ti yoo ṣi ikẹkun, lati ṣi ohun naa, ki o lee wọle. Ohun ti a nilo loni kọ ni ki a maa gbadura fun afikun agbara. Ẹ ni agbara ti o to lati ṣẹda aye titun. Ohun ti ẹ nilo ni igbagbọ lati lo agbara naa. Ohun ti ẹ nilo ni lati ṣe akoso iye naa, ki ẹ si gbe igbe aye iwa bi Ọlọrun, to bẹẹ gẹẹ ti ẹ ba beere ohunkohun lọwọ Ọlọrun, ẹ mọ eyi! A ni igboya ninu Ọlọrun. A mọ pe ti a ba pa awọn ofin Rẹ mọ, Oun ki yoo pa ohun rere kan mọ kuro lọdọ wa - ti a ba ba A rin. Ọlọrun n ba wa rin. Ah, akiika!

78 Wọn ni ohun kanṣoṣo lati ṣe. Wọn ni ohun kanṣoṣo lati ṣe, eyi ni ki wọn o duro si oju ọna. Ki i ṣe ki a ṣako lọ si ibiyi ati ibẹyẹn; ṣugbọn ki a duro si oju ọna Rẹ. Ijọ ni ohun kanṣoṣo lati ṣe, eyi si ni lati duro si oju ọna Rẹ. Wọn ni ọwọn ina kan, nipa eyiti wọn yoo fi arawọn si oju ila Ọlọrun. Bi wọn ba ti n tẹle ọwọn ina naa, ohun ti o dari wọn niyi. Aworan ti wọn lee ri ni ọwọn ina. Wọn ri i to n siṣẹ nipasẹ Mose, wọn si mọ pe oun ni adari awọn.

Loni, a ni Ọrọ naa. A n tẹle Ọrọ naa. A si ri Ọrọ naa to n siṣẹ ninu awọn onigbagbọ, a si mọ pe o ri bẹẹ. Ọlọrun n siṣẹ pẹlu wa, O n fi Ọrọ naa mulẹ pẹlu awọn iṣẹ ami to n tẹle wọn! A duro ti Ọrọ naa. Ọrọ naa n mu èsì wa.

Wọn duro ti Mose nitoripe ... Ọwọn ina naa - Mose tẹle e, awọn pẹlu si tẹle e. Nigbati wọn bẹrẹ si kọyin si Mose, ti wọn si n kún si Ọlọrun ati lodi si Mose, ti wọn yà kuro lọdọ Ọlọrun, si ibikan ati omiiran. Iṣoro wọle wa. Dajudaju.

79 A n duro ti Ọrọ naa, Ọrọ naa si n mu awọn iṣẹ ami wa. Jesu wipe, “Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ. Ṣe ẹ rii ... Duro ti Ọrọ naa, Ọrọ naa yoo mu awọn iṣẹ-ami Rẹ jade.

Ṣugbọn, Mose, ki ni ohun ti o ṣe? Wọn ṣáko kuro, ki ni ohun ti wọn ṣe? Wọn kuro ni ipa Ọlọrun, wọn si padanu isun omi wọn.

Mo ro pe ohun ti ijọ ti ṣe loni niyi. Wọn ti yà kuro ni ipa Iwe Mimọ. Wọn ti wọ inu awọn ẹkọ asan lọ. Wọn ti ya sinu awọn ohun kekeke ti ko tọ fun wọn lati ṣe. Wọn tẹwọgba awọn ohun kan. Wọn tẹwọgba awọn ẹkọ bi Adamọ awọn Apọsteli. Nibo ni ẹ ti ri eyi ninu Bibeli? Wọn gba awọn adabọwọ ti wọn ka. Wọn tẹwọgba ijọ ẹlẹkọ adamọ dipo iriri kan. Wọn gba bibọ-ọwọ dipo didi-atunbi. Wọn gba wiwọn omi si ni loju dipo itẹbọmi. Wọn gba ẹkọ eṣu tii, “Baba, Ọmọ, ati Ẹmi Mimọ,” nigbati ko si iru rẹ ninu Bibeli. Bibeli sọ pe, “Ni orukọ Jesu Kristi.” Oun kanṣoṣo ni o ni lati ṣe ti o ba fẹ omi yi kannaa. Eyi ni lati pada si ipa igbaani lẹẹkansii. Ẹ pada ... Oun ko tii kuro nibẹ; O si wa nihin.

80 Ẹ gba ẹkọ adamọ dipo Kristi. Ẹ ṣako lọ sinu ohun iṣina.

Ẹnikan sọ pe, “Koburu, emi jẹ ti ijọ Mẹtọdisi.” Ẹlomiran sọ pe, “Emi jẹ Baptisti.” Iyẹn n fihan nigbana pe eyin ki i ṣe Kristẹni. Ti Kristi ni awa i ṣe. A jẹ Tirẹ. Iwọ wipe, “Bayi, emi jẹ Baptisti. Ti o ba ohun ti o jẹ niyi, iwọ kii ṣe ti Kristi, ti Baptisti ni ọ. O wipe, ”Koburu, ti ijọ to n fi ifedefọ ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ ni mi.“ Ti ẹ ba jẹ ti ijọ Pẹntikọsti, ohun gbogbo ti o jẹ niyi.

Ṣugbọn, ti o ba ni iriri Pẹntikọsti ... Ọrọ Pẹntikọsti ni yoo si mu iriri Pẹntikọsti wa. Ẹ tẹle ohun kannaa ti awọn ọmọ ẹyin ṣe, ẹ duro si iyara oke titi ti a o fi fi Ẹmi Mimọ kun yin.

Lẹyinnaa, ti ohun ti o ni ba ṣe lodi si Ọrọ Ọlọrun, ti Ẹmi inu rẹ ba tako ohun ti Ọrọ sọ, nigbana, ki i ṣe Ẹmi Mimọ. Ẹmi aimọ to n ṣe afiwe Ẹmi Mimọ ni. Eṣu to n fi ara Rẹ pe Ẹmi Mimọ ni. Ṣe ẹ ri ibiti a de lori rẹ?

81 Ah, awọn kan ninu wa n fedefọ. A ni iṣe ariwo pipa ati awọn nkan bẹẹ, a si ṣe awọn nkan wọnyi. A gba ohun gbogbo ti ko si ninu Iwe Mimọ laaye lati wa si inu ijọ. Nibo ni a ba eyi de loni? A ti pada si aginju miran, agbekalẹ ti ko ni imisi. A ṣe agbekalẹ nipa ọgbọn ori, a si padanu omi iye naa. Ohun ti ijọ Pẹntikọsti ṣe niyi. Nigbati o bẹrẹ sị se agbekalẹ nipa ọgbọn ori, o bẹrẹ si fọ́ idapọ, o si n sọ pe, “Koburu, bayi, ẹ ko ni darapọ mọ ọkunrin yi, ti o ba gba eyi gbọ.”

Tẹsiwaju, duro ti i, titi ti yoo fi wa sinu Ọrọ otitọ, imọ otitọ. Ohun ti o wu ki o jẹ, jẹki o lọ botiwu-kori. Sa tẹsiwaju ninu jijẹ arakunrin.

Ṣugbọn, ah, a ni lati ṣe agbekalẹ kan, ki a si sọ pe, “Koburu nitoripe iwọ ki i ṣe onigbagbọ to n pe Ọlọrun ni ọkan, iwọ ki i ṣe onigbagbọ to n pe Ọlọrun ni meji-lọ́kan, tabi mẹtalọkan, tabi bi eyi, awa ko ni darapọ mọ ọ.” Nigbana, ti a bạ se eyi, ki ni ohun ti a ṣe? A n mu arawa pada si aginju lẹẹkansii. Bẹẹ ni.

Ṣugbọn ranti eyi pe, nigbati Israẹli yẹsẹ kuro ni ọna naa, ọna si ilẹ ileri, apata naa ko fi wọn silẹ - o duro sibẹ. Bẹẹ ni omi naa. Bẹẹ ni Ẹmi Mimo, n duro sibẹ. A ko ni lati sako lọ nipa rẹ.

82 Bayi, nihin ni Ọlọrun ti n kọ wa ni ohun nla kan. Ọlọrun n kọ wa ni ẹkọ kan nihin. A lu Jesu lẹẹkanṣoṣo, ìnà Rẹ si fun wa ni iriri Pẹntikọsti, lẹẹkanṣoṣo, o si wa titi laelae. Bayi, nigbati a lu apata naa, a ko nilo lati lu U mọ.

Mose ṣe asiṣe nipa bi o ṣe lu U lẹẹkeji, eyito n fi ailera igbagbọ rẹ ninu etutu naa han. Ṣugbọn nigbati a lu Kristi lẹẹkanṣoṣo, a ko ni lati lu U mọ titi laelae. Koburu, ki ni ohun ti Mose n ṣe? Mose n ṣe agbekalẹ ohun tuntun kan, o n gbiyanju lati ṣe ohun tuntun kan.

Ọna ti awọn alufa wa si ti gba ṣe e loni niyi. Wọn ti gbiyanju lati ṣe ohun tuntun kan. “A ṣe agbekalẹ ijọ eniyan Ọlọrun funra wa.” “A o ṣe arawa ni ijọ Pẹntikọsti Ọlọrun.” “A o ṣe agbekalẹ Agbarijọ Igbimọ Ijọ funrawa.” “A o ṣe eyi, iyẹn, tabi omiiran fun arawa.” Ki i ṣe ohun ti Ọlọrun ṣe niyi. Iyẹn ki i ṣe ohun ti Ọlọrun ṣe niyi. Iyẹn ki i ṣe ero Rẹ.

83 A lu Kristi lẹẹkanṣoṣo. Iyẹn ni ojulowo iriri. Iyẹn ni ojulowo ọna. Ni ọjọ Pẹntikọsti, Peteru sọ pe, “Ẹ ronupiwada, olukuluku yin, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi.”

A n wọn omi si eniyan loju ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ, a mu oniruuru adamọ ati ohun gbogbo wa nipa rẹ. Nigbati a kuro ninu Ọrọ naa, abajọ ti a ko lee de ibikibi.

84 Ọlọrun nkọ wa ni ẹkọ kan. Ko yẹ fun Mose lati sọ pe, “Bayi a o bẹrẹ ohun tuntun kan nihin bayi, a o si ṣe agbekalẹ kan, a o si da ijọ Katoliki silẹ.” (Ohun akọkọ ti wọn ṣe niyi.) Rara. Lẹyin igba diẹ, “Koburu, a o bẹrẹ ohun tuntun kan lati inu iyẹn, a o ṣe agbekalẹ awọn ijọ Luta.” Lẹyinnaa ni ijọ Angilika wa, lẹyinnaa ni Baptisiti, ati awọn miran. Awọn Kampbelli, ati ijọ Kristi, ati aṣodi si Kristi, ati ohun gbogbo yooku. Ṣe ẹ rii, gbogbo wọn

bẹrẹ si lọ, ni ọkọọkan, ni ọkọọkan, wọn n ṣe agbekalẹ ijọ ẹlẹyamẹya ati ẹgbẹ eniyan. Ki i ṣe bẹẹ. Ẹ wo ohun ti wọn n ṣe? Wọn nlu apata naa lẹẹkan sii, lati bẹrẹ ohun titun kan. A ko nilo ẹkọ tuntun.

85 Gbogbo eniyan ninu Bibeli ni a baptisi ni orukọ Jesu Kristi. Gbogbo eniyan ninu Bibeli ti wọn gba Ẹmi Mimọ wa si ọna Ọlọrun, bi Ọlọrun ti ṣe gẹlẹ ni ibẹrẹ. Wọn ṣe ohun kannaa. Wọn ni iriri kannaa. Ami kannaa tẹle wọn, iṣẹ kannaa tẹle wọn. Eeṣe? Wọn wa laaye nipa apata naa. Wọn ni omi kannaa.

Ati loni, idi ti a fi ni ọpọlọpọ ẹkọ adamọ ati oniruuru ijọ nipe a n bẹrẹ ohun tuntun. A ko nilo ohun tuntun kan. Ẹ pada si ibẹrẹ!

Ko yẹki Moṣe lu apata naa lẹẹkansii, lati bẹrẹ ohun tuntun kan. O yẹki o sọ fun wọn nipa ojulowo apata naa nikan. Ah, mo nireti pe ẹ loye eyi! O yẹki Mose sọ nipa ojulowo apata naa, ki i ṣe pe ki o lu u lẹẹkansii. Ki i ṣe pe ki o bẹrẹ ohun tuntun kan ṣugbọn ki o sọrọ si ohun igbaani.

86 Ọlọrun, ranmilọwọ, bi n ó tilẹ ku bi oniwaasu akuṣẹ lori pẹpẹ, n o maa sọrọ nipa apata atijọ naa! N o sọrọ nipa iriri ibẹrẹ pẹpẹ. N o sọrọ nipa Iwe Mimọ igbaani ti o fun awọn ẹni iṣaaju ni Ẹmi Mimọ: "Ẹ ronupiwada, olukuluku yin, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹṣẹ yin, ẹyin yoo si gba ẹbun Ẹmi Mimọ. Omi naa to n fi igba-gbogbo sàn jade lati inu apata naa wà pẹlu wa sibẹ. Yoo mu ohun kannaa wa. Yoo mu awọn iran wa. Yoo mu iwosan wa. Yoo mu awọn asọtẹlẹ wa. Yoo mu ohun gbogbo ti wọn ṣe nigbaani wa.

87 Nigbati Israẹli pada si ilana Iwe Mimọ lẹẹkansii, ti wọn si pada si oju ọna naa, wọn pada lọ si ilẹ ileri, ṣugbọn o gba wọn ni ogoji ọdun.

Pẹntikọsti ti rín-rìn kiri fun nkan bi ogoji ọdun ninu aginju. Ẹ pada wa sibi apata naa! Ko jinna si yin rara. Ohun niyi, a kọ ọ sinu Ọrọ nihin. Ẹmi Mimọ wa nihin to n ṣe ohun kannaa ti O n ṣe ni igbaani, bẹẹni omi naa to n fi igba-gbogbo wá, wa nihin. Ṣa a pada wa si ọdọ Rẹ, ẹ pada wa si ibi atijọ, tii ṣe ojulowo.

88 Bawo ni o ti ri ni ibẹrẹ?

"Koburu, wọn bọ oniwaasu lọwọ." Ko si ohun ti o jọ eyi." A baptisi wọn ni orukọ Baba, Ọmọ, ati Ẹmi Mimọ." Ko si ohun ti o jọ eyi. Ẹnikẹni nibikibi ninu Bibeli, tabi ni nkan bi ọọdunrun ọdun lẹyin ti a ti kọ Bibeli tan, ti a baptisi ni orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ. Ẹkọ adamọ Katoliki ni eyi, ki i ṣe ẹkọ Bibeli, ṣe ẹ rii

89 Wọn gba Ẹmi Mimọ. Ami wọnyi tẹle awọn ti wọn gbagbọ. Yoo ṣe bẹẹ lẹẹkansii. Apata naa jẹ ainipẹkun bi O ti wa nigbaani, apata naa ti a lu.

Ẹ maṣe jẹki a sọ pe, "Koburu, iwọ wa sihin ki o si darapọ mọ ijọ Pẹntikọsti ti wa, ki o wọ ipele Pẹntikọsti ti a wa gbekalẹ." "Rara, iwọ wa, ki o si darapọ mọ ijọ Baptisti, tabi Mẹtọdisi, tabi ijọ awọn Alagba, tabi ijọ Katoliki." Ki ni eyi? Iyẹn ni ki a lu apata naa lẹẹkansii, ki a bẹrẹ lati maa ṣe ohun tuntun.

Ẹ sọ fun wọn pe, "Ẹ ronupiwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹ̀ṣẹ̀ yin, ami wọnyi ni yoo si maa ba awọn ti o gbagbọ lọ." Nigbana ni ẹ pada si oju ọna igbaani, ẹ pada si ibi omi kannaa. Omi kannaa yoo mu itura kannaa ti O mu wa ni igbaani wa loni. Yoo mu ohun kannaa wa si agọ ara. Yoo mu agbara ifọnumọ kannaa wa. Yoo mu agbara iwosan kannaa wa. Yoo ṣe ohun kannaa ti O ṣe nigbana, ti a ba lee pada sinu Ẹmi Kannaa.

90 Iye ti o wa ninu igi ajara yoo mu eso ajara wa. Ti o bą se bẹẹ ni ọdun to kọja, yoo ṣe ohun kannaa ni ọdun yi. Iyẹn ni ofin Ọlọrun. Ofin Ọlọrun nipe ti igi yi ba jẹ igi ajara, fi i silẹ, eso ajara ni yoo mu wa. Ẹ lee fi ẹka igi miran si ara Rẹ, ṣugbọn ẹ fi i silẹ, yoo pada di ajara kannaa.

Bẹẹni a ti ṣe adamọdi ijọ pẹlu ẹkọ ti o sọ pe ifedefọ ni a fi n ṣe ijẹri Ẹmi Mimọ, pẹlu ẹkọ ijọ Baptisti, ti ijọ Mẹtọdisi, ti ijọ awọn Alagba, ti ijọ angilika, ati awọn ẹkọ miran. Eeṣe ti ẹ ko fi i silẹ? Ẹ pada wa si ara igi ajara naa, yoo pada wa si inu agbara kannaa. Amin! Amin! Mo fẹran eyi.

91 Ẹ bẹrẹ ohun titun, ohun kannaa ti a ti ṣe. Ki i ṣe ki a maa gbiyanju lati fi aṣẹ wa han. "Dokita Lagbaja ati tamẹdo ni oludasilẹ ijọ nla. Eyi ati iyẹn, ti eyi ati iyẹn, ati iyẹn." Iyẹn ki i ṣe e.

Ohun ti Mose sọ niyi, "N o fi ohun ti mo lee ṣe han wọn. N o mu un wa botiwu-kori!" O lu u, ko jade wa, o pariwo lẹẹkansii." Fi ohun ti mo lee ṣe han." Ọlọrun si binu si i fun eyi.

Ṣe ẹ ko ro pe ... Ti ẹ ba di ẹkọ adamọ kan mu, Ọlọrun yoo binu si yin fun eyi. Bẹẹ gẹlẹ ni eyi ri. Ẹ ni lati pada si ojulowo. Ẹ pada wa.

92 Ti ẹ ba ba awọn eniyan naa sọrọ, ẹ maṣe sọ fun wọn pe, "Ẹ darapọ mọ ijọ wa. Wa ki ẹ si ṣe ijẹwọ adamọ wa." Ẹ wa ki ẹ si ronupiwada, ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹ̀ṣẹ̀ yin, ẹ o si gba

ẹbun Ẹmi Mimọ, ti ọkan yin ba tọna. Ami wọnyi ni yoo si maa ba awọn ti o gbagbọ lọ. Awọn onigbagbọ, ami wọnyi ni yoo maa ba wọn lọ. Eeṣe? Apata naa, apata ti a lu, ti omi iye inu rẹ si tu jade, O n ṣe ohun kannaa ti O ṣe nigbaani. Ko lee ṣe lai ṣe bẹẹ. Ah, bẹẹni.

A fẹ ṣe afihan, ki a si sọ pe, "Awa jẹ ti ijọ Mẹtọdisi ati Baptisti."

93 Ṣa ba Apata naa sọrọ, O wa ni arọwọto rẹ. Maṣe gbiyanju lati darapọ mọ ọn." Mo ni lati darapọ mọ ọn nihin." Ma gbiyanju lati darapọ mọ ọn. Iwọ ko lee darapọ mọ eyi, ohun kan ti o daju niyi. O lee darapọ mọ ijọ Mẹtọdisi, o lee darapọ mọ ijọ Baptisti, o lee darapọ mọ ijọ Pẹntikọsti, o lee darapọ mọ ijọ Angilika; ṣugbọn iwọ ko lee darapọ mọ eyi. Rara. A ni lati kun ọ pẹlu Rẹ ni. Maṣe darapọ mọ eyi; ki a kun ọ pẹlu rẹ. Koju bẹẹ lọ. Ki a kun ọ pẹlu ki ni? Pẹlu agbara, pẹlu Ẹmi, pẹlu iye, pẹlu ayọ, alafia, ipamọra, iwa-pẹlẹ, inu-rere, agbara Ẹmi Mimọ ninu aye rẹ, nitoripe ifarahan ayeraye naa wa nibẹ. Ranti ….

N o ni lati danu-duro nitoripe ọjọ ti lọ.

94 Ṣugbọn, ẹ ranti eyi pe, apata naa ko fi igbakan fi wọn silẹ. Ko fi wọn silẹ ri. Bẹẹ ni Kristi ko si ni fi wa silẹ laelae. Kristi wipe, "Emi yoo wa pẹlu yin nigba-gbogbo, ani titi de opin aye." Ṣe bẹẹ ni? Apata naa si duro ti wọn lati Horebu de Nebo. O ṣe bẹẹ. Titi de Jordani, O si wa nibẹ. Ọlọrun, mo fẹ rii ni Jordani.

Mose, nigbati o de Jordani, apata naa wa pẹlu rẹ de opin. O si n duro sibẹ, o n wo ọpọlọpọ eniyan ti wọn ti pada sẹyin, ti wọn si ti fi Ọlọrun silẹ. Ọkan rẹ n pongbẹ fun wọn. O si bojuwo Jordani. O wa ni Jordani. Mo n sọ nipa Jordani ti ẹmi. O n duro sibẹ, iku mbọ wa si i, sugbọn o wo o, o dubulẹ ni iha rẹ, nibẹ si ni apata naa wa. O kan gun ori apata naa, awọn angẹli si wa gbe e lọ.

95 "Nko ni fi yin silẹ, bẹẹ ni nko ni kọ yin silẹ." Botiwu ki igba le koko to, botiwu ki a ti dagba to, iru iku towu-ki a ku, ẹ ranti pe, apata naa yoo maa duro de wa ni Jordani. Ki yoo fi wa silẹ, tabi ki O kọ wa silẹ. Ẹ ranti eyi. Omi naa to n fi igba gbogbo wá lati inu apata yoo wa pẹlu wa ni gbogbo ọjọ aye wa, ati ni Jordani paapa.

96 Ẹ jẹki a tẹriba [Arakunrin kan lati inu apejọpọ jẹ́ iṣẹ́ kan nipa asọtẹlẹ.]

Nigbati Ẹmi naa si n rin laarin wa, Ẹmi Ọlọrun n rin laarin wa, njẹ a ri awọn kan laarin wa nihin ti wọn ko mọ Kristi, ti ẹ ko sunmọ apata naa, ti ẹ ko si ni idapọ pẹlu Rẹ ni owurọ yi? Ṣugbọn ti ẹ mọ pe O wa nihin. Ẹ wo O to n rin kaakiri, ẹ wo O to n rin kaakiri, ẹ wo o to n ba le awọn eniyan. Iyẹn ni ifarahan igba-gbogbo omi naa. Iyẹn ni igbala. Iyẹn ni Ẹmi to n kun agogo wọn de ipele kan ti wọn ko tilee pa ẹnu wọn mọ, ohun kan ni lati jade wa. Ti iwọ ko ba mọ ọn, ṣe iwọ yoo fẹ lati na ọwọ rẹ soke ki o si sọ pe, "Gbadura fun mi, Arakunrin Branham. Mo fẹ mọ ọn bayi. Mo si fẹ ba a sọrọ, mo si fẹ mọ ọn ni ẹkunrẹrẹ Ẹmi Rẹ. Mo fẹ mọ pe O wa ni ẹgbẹ mi, nigba-gbogbo. Mo gbagbọ pe O wa, ṣugbọn mo fẹ di ọrẹ Rẹ. Òùngbẹ Rẹ n gbẹ mi, ebi Ọlọrun si n pa mi. Mo fẹ mọ ọn si i?"

97 Ki Ọlọrun bukun ọ ṣa. Ki Ọlọrun bukun ọ, ṣa. Iwọ, arakunrin. Iwọ, bẹẹni, ni ẹyin lọhun. Nihin, arabinrin, bẹẹni, bẹẹni, arabinrin. A ri ọwọ yin, Ọlọrun pẹlu si ri wọn. Ki Ọlọrun bukun ọ, ọdọkunrin. Ki Ọlọrun bukun ọ. Iwọ, arabinrin. Amin. Ki Ọlọrun bukun ọ. Ki o di alabukun fun, arabinrin. Ṣe a ri ẹlomiran bi a ti wa ni idakẹjẹ. Ki Ọlọrun bukun ọ, lẹyin lọhun, ọdọkunrin.

Ronu nipa rẹ. Ronu nipa rẹ, omi to n fi igba-gbogbo wá lati inu apata. Ẹmi kannaa ti O pariwo jade ni ọjọ idajọ fun Un, nigbati O gba idajọ wa si ori ara Rẹ - ti ọ̀pá ibinu Ọlọrun si kọ lu U, ti a si fi ẹ̀ṣẹ̀ rẹ we ọpa naa, o si kọ lu U, ẹjẹ̀ ati omi si tu jade lati ara Rẹ - O wipe, "Baba, ni ọwọ Rẹ ni mo fi Ẹmi mi le." Lẹyinnaa ni ọjọ Pẹntikọsti ni O tọ wa wa lati maa lọ pẹlu wa ni gbogbo irinajo naa. O si sunmọ wa bayi.

98 Nigbati o ba ti sakuro ni abẹ ifarahan Rẹ, ti o ti jinna rere si ile, sọ bayi Pe, "Oluwa, mo n padabọ wa si il." Nigbati a n kọ orin yi, ti iwọ yoo ba fẹ lati wa si ori pẹpẹ, ki o si ya ọkan ara Rẹ si mimọ pada fun Kristi ... Amin.

Mo ṣako jinna si Ọlọrun,

(Mo ti kuro ni oju-ọna Rẹ)

Mo ... nbọ wale bayi;

Mo ti pẹju ni ọna ẹ̀ṣẹ̀ (aigbagbọ)

Jesu mo n bọ wale

Mo n pa-da bọ wale

Nko ni ṣako mọ,

Na ọwọ ifẹ Rẹ si mi

Jesu mo n pada bọ.

[Arakunrin Branham n kùn si orin naa "Jesu mo n bọ wale."]

99 Awọn ọdọkunrin mẹta rin jade wa sita, kiakia, pẹlu omije ni oju wọn, wọn si kunlẹ si ẹba pẹpẹ. Lootọ, a ti dariji wọn. A ti dariji wọn ki wọn to dide wa, nigbati wọn ṣe ipinnu ninu ọkan wọn. Wọn kan jade wa lati kunlẹ sihin lati jẹki awọn eniyan mọ iha ẹniti wọn wa lati isisiyi lọ.

Boya, awọn agbalagba kan yoo wa ti yoo fẹ lati ṣe eyi, lati kunlẹ ki wọn o si sọ pe, "Oluwa, mo ti ṣako jinna kuro ni ọna Rẹ. Mo ti ṣe ọpọlọpọ iyemeji, nigbakan mo ṣako lọ, mo si bọ sinu ẹ̀ṣẹ̀. Mo fẹ pada si ọdọ Rẹ ki o to pẹ ju. Ọlọrun, n o fẹ lati wa. N o fẹ lati wa ki n si kunlẹ."

100 Bayi, bi o ti ṣajeji to, awọn ọdọbinrin mẹta ti wọn ni ọjọ ori bi ti awọn ọdọkunrin naa jade wa, wọn si kunlẹ.

Mo gbagbọ pe ọkan ninu wọn jẹ ọmọdebinrin ti o ṣẹṣẹ ni aburo ọkunrin ni ile. Ni ọjọsi ti ... Iyafin Wood wa, o si sọ fun mi pe, arabinrin wa kan nlọ si ile iwosan lati bi ọmọ tuntun. Ẹmi Mimọ sọ pe, "Lọ sọ fun wọn pe ọmọkunrin ni yoo jẹ." Nigbati o si bii, o jẹ ọmọkunrin.

O da bi ẹnipe awọn ọmọde ni owurọ yi wa fun, awọn ọmọde n jade wa lati ile ẹkọ ọjọ isimi ti Arabinrin Arnold, wọn ya ara wọn si mimọ si Ọlọrun.

Apa ọtun mi niwaju pẹpẹ kun fun awọn ọmọde. Yoo dara ti a ba lee kọ orin igbaani kan, ni ori pẹpẹ, si awọn eniyan yooku (Ṣe bẹẹ kọ?), awọn agbalagba.

101 Bayi, Oluwa, mo nbọ wale

[Arakunrin Branham n ba awọn ọmọde sọrọ lori pẹpẹ.]

Mo ṣako jinna si Ọlọrun,

Mo ... nbọ wale bayi;

Mo ti pẹju ni ọna ẹ̀ṣẹ̀

Jesu mo n bọ wale

Mo n pa-da bọ wale

Nko ni ṣako mọ,

Na ọwọ ifẹ Rẹ si mi

Jesu mo n pada bọ.

102 Ẹ jẹki a tẹriba fun iṣẹju diẹ lati gbadura fun awọn ọdọ wọnyi.

Baba ọrun, ti ọjọ iwaju yoo ba wa, ti Jesu yoo ba fa bibọ Rẹ sẹyin fun ọdun mẹwa tabi mẹẹdogun si asiko yi, awọn wọnyi ni ọdọkunrin ati ọdọbinrin ti yoo gbe iwaasu yi tọ awọn iran miran to mbọ wa lọ. Ko si iyemeji ninu ọkan mi, Oluwa, ṣugbọn mo ni igbagbọ pe ni ọjọ aye wọn gbogbo, wọn yoo ranti bi wọn ṣe wa si ori pẹpẹ yi loni. Wọn jẹ ọ̀sọ́ Rẹ kekeke, Oluwa. Ọkan wọn kekere ti o jẹ ọkan ẹran ni Iwọ ti fọwọ́tọ́ ni owurọ yi. Kii ṣe pe wọn tilẹ gbọ gbogbo iwaasu yi, wọn wa lati iyara ile ẹkọ ọjọ isimi wọn nibiti wọn ti kẹkọ lati ẹnu Arabinrin wa Arnold, wọn si wa tarata sihin, wọn fi ọkan wọn kekere fun Ọ.

Bayi, Baba, mo ṣẹṣẹ pari sisọ Ọrọ naa pe, ninu wa ni Ẹmi Mimọ n gbe. Ati Ẹmi Mimọ yi, igbagbọ ninu Ẹmi yi, ohun ṣe ohun gbogbo. Mo si gba eyi gbọ ni wakati yi, dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ti wọn ti da ji wọn. Mo si n bẹ̀ Ọ, pẹlu gbogbo igbagbọ ti o wa ninu mi, pe Iwọ yoo pa aye wọn mọ ni oju-ọna naa. Maṣe jẹki wọn o ya kuro ni ọna Rẹ.

103 Eyi jẹ ohun to ṣajeji lootọ. Ẹmi sọrọ ni owurọ yi pe a o ri ohun kan to ṣajeji. Ọlọrun, ti Iwọ ba ti dẹkun bíbá awọn yooku sọrọ, koju si awọn ọmọde. Bi o ti jẹ pe ni owurọ yi ni ori pẹpẹ, ko si agbalagba kan ti o wa, ṣugbọn ẹgbẹ awọn ọmọde ni o wa. Sibẹ, pẹlu iwaasu nla ti o ṣoro lati loye, si awọn agbalagba paapa, ṣugbọn awọn ọmọde gba Ẹmi ti iwaasu naa mu wa. A dupẹ lọwọ Rẹ fun wọn, Baba. Mo fi wọn fun Ọ, bi iranṣẹ Rẹ, gẹgẹ bi èrè ipade yi, lati maa ranti pe iye omi naa to n fi igba-gbogbo wà yoo maa ṣàn pẹlu wọn ni gbogbo ọjọ aye wọn. Jẹki wọn o ni igbagbọ nisisiyi ninu ohun to ṣẹlẹ yi, pe Ọlọrun ti o fa wọn lati ori ijoko wọn, ti O si mu wọn wa sihin, ki wọn ki o ni igbagbọ ninu Ọlọrun yi ni ọjọ aye wọn gbogbo. Jẹki a mu ẹmi

wọn kekere wọnyi tọ Ọ wa ni ọjọ iku wọn, ki a si mu pada tọ ara wọn wá ni ọjọ ajinde. TiRẹ ni wọn i ṣe. A fi wọn fun Ọ nipasẹ orukọ Jesu.

104 Nigbati a n tẹriba sibẹ, n o bi gbogbo awọn ọmọde wọnyi ti o wa lori pẹpẹ, ti wọn gbagbọ pe Jesu ni Olugbala awọn, ati Ẹmi naa ti O sọ fun yin ninu apejọpọ lati wa sihin, ki ẹ si kunlẹ si ori pẹpẹ, “Njẹ ẹ gbagbọ pe Jesu fẹran yin, O si dari ẹ̀ṣẹ̀ yin ji yin?” Mo fẹ ki ẹ dide lori ẹ̀ṣẹ̀ yin, ki ẹ si dide lori ẹsẹ yin, o dara, ki ẹ si wo ẹyin yin, ki ẹ wo apejọpọ. Gbogbo ẹyin ọmọdekunrin ati ọmọdebinrin ti o fẹran Jesu, ẹ dide, ki ẹ si wo ẹyin, ki ẹ wo apejọpọ, ẹnikọọkan yin.

105 Ẹyin ọmọdebinrin ti ẹ wa niwaju nkọ? Njẹ ẹ gbagbọ? Njẹ ẹ fẹran Jesu? Ẹyin ọmọdebinrin ti ẹ wa nihin, njẹ ẹ fẹran Jesu pẹlu gbogbo ọkan yin? Njẹ ẹ fẹran Rẹ? Njẹ ẹ fẹran Rẹ? Ṣe iwọ fẹran Rẹ pẹlu, Olufẹ? Dide nihin, jẹki awọn eniyan mọ pe o fẹran Jesu. Ki Ọlọrun bukun yin.

Bayi, ẹ jẹki a wo ibiyi, ki a kọrin fun awọn eniyan wọnyi ki a to lọ, “Jesu fẹ mi mo mọ bẹẹ. Bibeli sọ fun mi bẹẹ.” Ṣe ẹ rii? Ẹ jẹki a gbe ọwọ wa soke bi a ti n kọ orin naa bayi. O dara, ẹ jẹki a kọ ọ.

Jesu fẹ mi, emi mọ;

Bibeli lo sọ fun mi

TiRẹ l'awọn ọmọde

Wọn ko lagbara Oun ni.

Bayi, ẹ gbe ọwọ yin soke bi a ti nkọrin. Ẹ jẹki a kọ ọ papọ.

Ha! Jesu fẹ mi

Ha! Jesu fẹ mi

Ha! Jesu fẹ mi

Bibeli sọ fun mi

106 Bayi, ki gbogbo yin sọ eyi tẹle mi. Mo gbagbọ pe Jesu Kristi ni Ọmọ Ọlọrun. Loni, mo gba a bi Olugbala mi. Lati oni lọ, Emi yoo fẹran Rẹ, n o si sin In. Amin.

107 [Arakunrin kan ninu apejọpọ sọ pe, “Arakunrin Branham, mo ni awọn ọmọ mẹrin ni ọkan mi nisisiyi. Ṣe iwọ yoo gbadura fun wọn?”] Dajudaju, n o ṣe bẹẹ, Arakunrin Ben.

Baba ọrun, ọkunrin yi ri awọn ọmọde yooku to n tọ Kristi wa, oun pẹlu si ke jade, gẹgẹ bi baba, fun awọn ọmọ rẹ. Ẹmi ti o si mu awọn ọmọde wọnyi wa si ori pẹpẹ, jẹki Ẹmi kannaa gba awọn ọmọ rẹ la, Oluwa. Ṣe e. A fi wọn le Ọ lọwọ, baba, lorukọ Jesu Kristi.

108 Bayi bi ẹyin ọmọde wọnyi ṣe n pada si ori ijoko yin, mo fẹ ki gbogbo eniyan ti o wa ni ori ila yi bọwọ pẹlu awọn ọmọde wọnyi, tabi ki ẹ fi ọwọ gba wọn lẹyin bi wọn ti n lọ. Ki gbogbo yin maa pada lọ si ori ijoko yin ni ọna yi. Ki ẹ si jẹki gbogbo eniyan ti o wa nibẹ fi ọwọ wọn gba awọn ọmọde naa lẹyin. A si fẹran yin pẹlu gbogbo ọkan wa. Gbogbo yin ni aṣoju ninu ara Kristi, ẹ wa ninu Rẹ pupọ bi awa yooku.

A n yan ... lọ si Sion

Si...oni to dara ju ...lọ;

Awa n goke lọ si Sion

Ilu ti o dara julọ

Ẹyin tẹ fẹ Jesu

Ẹ fi ayọ yin han

Jẹ ka jumọ kọrin didun (2ce)

Ka si y'itẹ naa ka (2ce)

Orin alayọ nla! Ẹ jẹki a gbe ọwọ wa soke bayi.

A n yan ... lọ si Sion

Si...oni to dara ju ...lọ;

Awa n goke lọ si Sion

Ilu ti o dara julọ

Ẹ jẹki a bọ ara wa lọwọ bi a ti nkọrin bayi.

A n yan ... lọ si Sion

Si...oni to dara ju ...lọ;

Awa n goke lọ si Sion

Ilu ti o dara julọ

109 Bayi, ẹ jẹki a duro pẹlu ori wa ti a tẹba, nigbati a n gbadura. Arakunrin Teddy..

Mo ni awọn ẹbẹ adura kan nihin, awọn aṣọ inuju kan ati bẹẹ bẹẹ lọ. Wọn lee ti fi wọn ranṣẹ lati oke okun. Billy n sọ fun mi pe awọn gba bata ẹsẹ ọmọde lati orilẹ ede Gẹẹsi, bi o ti jinna to, ọmọ naa jẹ arọ. A si ni lati gbadura si eyi pẹlu.

110 [Arakunrin Ben sọ pe, "Arakunrin Branham, jọwọ foriji mi pe mo fẹ sọrọ, ṣugbọn gbadura pe ki Ọlọrun ṣe afihan ẹniti o kọlu ọkọ̀ wa laṣalẹ ana nibi iwaju ọkọ mi, ni apa-ọtun, gbadura pe Ọlọrun yoo ṣe afihan eniyan naa. Gbadura pe ki Oluwa fihan."] Amin, Arakunrin Ben, n o ṣe bẹẹ dajudaju.

[Arakunrin Branham n tẹsiwaju lati maa kùn si orin naa, "A n yan lọ si Sioni."]

111 Bi a ti n yan lọ, Oluwa, a mọ pe apata naa ti a lu wa pẹlu wa, ifarahan igba gbogbo ti omi naa to n ti inu apata wa n lọ pẹlu ijọ. Iwọ Ọlọrun ainipẹkun, tu igbagbọ ninu Ọlọrun yi ti O wa pẹlu wa sinu wa ni owurọ yi. Mo mọ pe Iwọ yoo ṣe bẹẹ, bi a ti lee ri oju rere ni oju Rẹ, ti Iwọ fi lee fi si ikawọ wa. Ti iwọ yoo ba fifun wa lẹkunrẹre, a lee ṣi i lo, Oluwa. Ṣugbọn bi a ti ri oore-ọfẹ gba lati ọdọ Rẹ, jẹki o ṣẹlẹ.

Arakunrin wa sọ pe ẹnikan kọlu ọkọ̀ oun. Ọlọrun, a mọ pe ọkunrin naa ko ni owo lati ṣe atunṣe awọn ohun to bajẹ lara ọkọ naa. Mo gbadura pe Iwọ yoo fi ọwọ tọ eniyan naa, tabi wa si ipo ti o fi lee ronupiwada lori ohun ti o ṣe yi, ki o wipe, "Arakunrin, emi yoo ṣe atunṣe ọkọ rẹ. Emi ni mo kọ lu u." Ran Arakunrin Ben ati awọn olufẹ rẹ lọwọ.

112 Ni ọwọ mi ni awọn aṣọ inuju ati ẹbẹ adura kan wa, a ni igbagbọ ninu Ọlọrun naa. Mose ni igbagbọ ninu Ọlọrun naa, o si la okun pupa ja. Daniẹli ni igbagbọ ninu Ọlọrun naa, a gba a la kuro ninu iho kiniun. Shedraki, Messaki ati Abedinego ni igbagbọ ninu Rẹ, wọn si pa ina naa. Paulu ni igbagbọ ninu Rẹ, ni ọjọ kan, nigbati isọji nla nlọ lọwọ, ti Paulu ko si lee de ọdọ gbogbo eniyan, o kan mu aṣọ inuju o sọ pe, "Mo gbagbọ pe Ọlọrun wa pẹlu mi." O gbe ọwọ rẹ le awọn aṣọ inuju ati aṣọ awọleke, awọn ẹmi aimọ si fi awọn eniyan naa silẹ, awọn aisan, ati awọn arun si fi wọn silẹ. Ọlọrun, emi pẹlu si ni igbagbọ ninu Ọlọrun kannaa. Jẹki ẹmi aimọ fi wọn silẹ. Awọn aisan, ati awọn arun, ati inira, jẹki wọn o fi awọn eniyan naa silẹ, Oluwa.

113 Iwọ ni Ọlọrun kannaa ti O ba mi sọrọ ninu ọwọn ina naa, nibi odo naa lọjọsi. Iwọ ni a fi aworan Rẹ ti O ya pẹlu mi kọ si ara ogiri nihin. Iwọ wa pẹlu wa, Oluwa. O wa nigba-gbogbo, Iwọ ẹnitiṣe ọwọn ina kannaa. A si ti gbadun omi kannaa ti o ti inu apata naa wa lojoojumọ, bi a ti darapọ mọ ọn ninu Ẹmi. Lẹyinnaa, Iwọ wa nihin. A ni igboya ninu Rẹ, Oluwa. A ni igbagbọ ninu Rẹ. A gbagbọ pe Iwọ yoo ta ororo le wa lori, atipe Iwọ yoo ran wa lọwọ. Ki i ṣe fun ogo ti wa, Oluwa. Awa yoo da bi Mose nigbana, nigbati o ṣe ohun to lodi, ti awa ba se e fun ogo ara wa. A fẹ ṣe ohun kan lati ran Ọ lọwọ, Oluwa. Eyi ni èrò ọkan wa. Ti a ba si lee ṣe e, fihan wa, Baba, ohunkohun ti Iwọ ba fẹ ki a ṣe.

114 Nisisiyi, fun iṣe igbagbọ, mo ba awọn aisan ti awọn aṣọ inuju yi duro fun, ati awọn ẹbẹ adura wọnyi. Awọn aisan naa yoo fi awọn eniyan naa silẹ. Mo mọ pe Iwọ yoo ṣe e, Oluwa. Mo gbaagbọ ninu ọkan mi pe Iwọ yoo ṣe e. Wo gbogbo aisan ti o wa laarin wa lowurọ yi san.

Gba gbogbo awọn ti o na ọwọ wọn soke la, ki wọn o lee fẹ lati tọ apata naa wa fun omi naa. Ọlọrun, jẹki oungbẹ gbẹ wọn pupọ loni, jẹki awọn iyọ aye yi wọn ka, eyi yoo mu ki wọn o pongbẹ fun Kristi. Ṣe e Oluwa.

Wa pẹlu wa ni aṣalẹ yi, Baba. Ọlọrun, jẹki n mọ nipasẹ awọn ibeere naa, ohun ti o wa ni ọkan awọn eniyan naa. Ti ko ba si ohunkohun ni ọkan wọn, lẹyinnaa, Oluwa, fun mi ni iwaasu ti n o ṣe fun ọkan wọn laṣalẹ yi.

115 Bukun Arakunrin Neville wa, ati iyawo rẹ, ẹbi rẹ, ijọ wa kekere yi, awọn alamojuto wa, awọn diakoni wa, awọn ọmọ ijọ wa, ati ara Rẹ nibi-gbogbo. Wa pẹlu wa, Baba. A fi eyi si ọwọ Rẹ Oluwa, ni orukọ Jesu Kristi.

A n yan ... lọ si Sion

Si...oni to dara ju ...lọ;

Awa n goke lọ sis ion

Ilu ti o dara julọ

Bayi, ẹ jẹki a kọ ọ, dajudaju si i nisisiyi, ṣe ẹ rii.

Ẹyin tẹ fẹ Jesu

Ẹ fi ayọ yin han

Jẹ ka jumọ kọrin didun (2ce)

Ka si y'itẹ naa ka (2ce)

Pẹlu ọkan wa ti a tẹba nisisiyi.

A n yan ... lọ si Sion

Si...oni to dara ju ...lọ;

Awa n goke lọ si Sion

Ilu ti o dara julọ

MESSAGE hub online

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info